# Ojú Àmúwòyè Ètò Ọrọ̀-Ajé Aáfíríkà 2019

## Ìṣesí Ètò Ọrọ̀-Ajé àti Àfojúsùn fún Ìtẹ̀síwájú rẹ̀

## Ìpèsè Iṣẹ́, Ìdàgbàsókè àti ilé-iṣẹ́ tó Fẹsẹ̀múlẹ̀

## Àjọṣepọ̀ Fún Ìtẹ̀síwájú Ọrọ̀-Ajé Aáfíríkà



AFRICAN DEVELOPMENT BANK GROUP

# ÌTỌ́KASÍ KÓKÓ-ÈRÒ

Ìwòye ètò ọrọ̀-ajé Aáfíríkà lọ́dún yìí ṣe àgbéyẹ̀wò ìdàgbàsókè ètò ọrọ̀-ajé alákòóyawọ́ lágbàáyé, ìrísí rẹ̀ ní ilẹ̀ Aáfíríkà, pẹ̀lú àfojúsùn ipa tí àìkójú-òsùnwọ̀n rẹ̀ ní sí òde àgbáyé, lórí ìdàgbàsókè àti ìṣòro tó rọ̀ mọ́ àìrówó-ná lápapọ̀ (Orí Kìn-ín-ní). Bákan náà ni ìwòye alàyé yìí sọ̀rọ̀ nípa ìpèsè iṣẹ́ nípasẹ̀ ètò aláyìípadà tó fẹsẹ̀múlẹ̀, tó sì dúró déédé nínú àtúpalẹ̀ náà (Orí Kejì). Àtúpalẹ̀ ìwòye yìí tún ṣe àyẹ̀wò ètò ọrọ̀-ajé tó pè fún àjọṣepọ̀ àwọn ènìyàn ẹsẹ̀-kùkú, káàkiri agbègbè ní ilẹ̀ Adúláwọ̀ ní Aáfíríkà, àti òfin àtẹ̀lé tó lè mú kí ìdàgbàsókè bá ètò ọrọ̀-ajé (Orí Kẹta).

### ÌṢESÍ ÈTÒ ỌRỌ̀-AJÉ AÁFÍRÍKÀ LÁGBÀÁYÉ ÀTI ÀFOJÚSÙN FÚN ÌTẸ̀SÍWÁJÚ RẸ̀

Ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé ilẹ̀ Aáfíríkà ń tẹ̀síwájú láti máa gbèrú àti láti gba agbára sí i pẹ̀lú àfihàn ìpín mẹ́ta-ààbọ̀ nínú ìdá ọgọ́rùn-ún tí ó dé ní ọdún 2018, ní èyí tí ó fẹ́rẹ̀ dà bí i rẹ̀ ní ọdún 2017, tí ó sì ti gbéra dé ìdá kọ́tà kan nínú ọgọ́rùn-ún; láti orí ìdá kan-ó-lé-méjì ní ọdún 2016. Ìlà Òòrùn Aáfíríkà gbé ipò aṣaájú, nígbà tí *GDP* wọ́n wà ní ipò ìdàgbàsókè onídàá márùn-ún-lé-ẹyọ-méje nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ní ọdún 2018. Àríwá ilẹ̀ Aáfíríkà ló tẹ̀ lé wọn, nígbà tí ìdá ti wọn jẹ́ ìdá mẹ́rin-ó-lé-ẹyọ mẹ́sàn-án nínú ìdá ọgọ́rùn-ún. Ìwọ̀ Oòrùn Aáfíríkà wà ní ipò onídàá mẹ́ta-ó-lé-ẹyọ-mẹ́ta, nígbà tí ààrin gbùngbùn Aáfíríkà wà ní ìdá méjì-ó-lé-ẹyọ-méjì. Àwọn ti Gúúsù Aáfíríkà wà ní ìdá kan-ó-lé-ẹyọ-méjì péré, nínú ìdá *gbogbo* ọgọ́rùn-ún náà.

Ní kúkúrú ìsọ, a wòye pé ìdàgbàsókè tó gbéra kánkán ti ṣẹlẹ̀ láti ipò tó wà lọ sí ìdá mẹ́rin nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ní ọdún 2019; tí ìwòye ìyàtọ̀ ìdá mẹ́rin-ó-lé-ẹyọ-kan sì máa wáyé ní ọdún 2020. Lóòótọ́, ìwòye wa ni pé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìgbèrúsókè ọrọ̀-ajé Aáfíríkà kéré sí ti Orílẹ̀-èdè China àti India lọ, a rí Aáfíríkà gẹ́gẹ́ bí i àwùjọ tó gbèrú ju àwọn Orílẹ̀-èdè mìíràn tó sèsẹ̀ ń dìde nílẹ̀ àti àwọn mìíràn tí wọ́n ti gbéra ju àwùjọ Aáfíríkà lọ. Àmọ́, ìwọ̀nyí kò tó láti tẹ̀rì pátápátá nínú àìpèsè-iṣẹ́ àti àìní rárá. Nínú àfojúsùn ìdá mẹ́rin ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé ilẹ̀ Aáfíríkà ní ọdún 2019, Àríwá Aáfíríkà ni a wòye pé ó yẹ láti ṣe ìjábọ̀ àfikún ìdá kan-ó-lé-ẹyọ-kan tàbí ìdá ogójì nínú ìdá ọgọ́rùn-ún náà. Sùgbón, ìlàjì ìdàgbàsókè *GDP* ní Àríwá Aáfíríkà

báyìí kò ṣe déédé rárá; nítorí àyípadà ńlá, tí ó ti ń dé bá ọrọ̀-ajé àti ètò ìsúná Orílẹ̀-èdè Libya báyìí.

Ìlà Òòrùn Aáfíríkà, gẹ́gẹ́ bí i àwùjọ tí ó yárá láti gbèrú jù lọ, jẹ́ agbègbè tí a wòye pé ó yẹ kí ó ní ìtẹ̀síwájú bí i ìdá márùn-ún-ó-lé-mẹ́sàn-án ní ọdún 2019 àti ìdá mẹ́fà-ó-lé-ẹyọ-kan ninu ìdá ọgọ́rùn-ún ní ọdún 2020. Láàrin ọdún 2010 sí ọdún 2018, ìgbérasọ tí ó tó ìlàjì ìdá mẹ́fà nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ni ó wáyé láàrin àwọn Orílẹ̀-èdè àgbáyé wọ̀nyìí: Dji-bouti, Ethiopia àti Rwanda; nígbà tí Tanzania ní àkọsilẹ̀ fifi ìdajì àmì ìtayọ yàtọ̀ nínú àkọsílè ìwoye wọn. Àmọ́, ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn Orílẹ̀-èdè àgbáyé mìíràn, tí a ti rí àrítọ́kasí bí i Orílẹ̀-èdè Burundi àti Comoros, ìjákulẹ̀ bá ìtẹ̀síwájú ọrọ̀-ajé wọn púpọ̀, nitorí ọ̀rọ̀ òṣèlú tí kò fara rọ ní agbègbè náà.

Ìdàgbàsókè tí ó wúni lórí ti ń gbéra sọ díẹ̀ díẹ̀ ní ààrin gbùngbùn Aáfíríkà, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, irú ìgbèrúsókè náà kéré sí àfojúsùn Àjọ Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà lápapọ̀. Gbígbéra sọ náà sì tún jẹ́ ìrànlọ́wọ́ láti ara ẹ̀dínwó àwọn ọjà àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ àmúgbòòrò ìpèsè àwọn nǹkan ọ̀sìn-àgbẹ̀.

Àfojúsùn wa ni pé, ó yẹ kí àmúgbòòrò ìtẹ̀síwájú tí ó bára jọ wà ní Gúúsù Aáfíríkà ní ọdún 2019 àti 2020 lẹ́yìn ìmọ̀lára ìdápadà-bọ̀sípò tí wọ́n ní, ní ọdún 2018. Ìfàsẹ́yìn nínú ìdàgbàsókè tí a ń rí ní ìhà Gúúsù Aáfíríkà ní nnkan ṣe pẹ̀lú àìní ìdàgbàsókè gidi tí ó yẹ fún Orílẹ̀-èdè South Aáfíríkà. Èyí sì ní ipa lára àwọn Orílẹ̀-èdè mìíràn tí ó yí South Aáfíríkà ká.

## Àwọn Èròjà Ìtukọ̀ Ìdàgbàsókè Ètò Ọrọ̀-Ajé Aáfíríkà ti ń dúró déédé

Láìpẹ́ yìí, àwọn èròjà ìtukọ̀ ìdàgbàsókè ètò ọrọ̀-ajé Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà ti n dúró déédé. Àwọn èròjà ajẹmọ́-ìlò àmúlò tí ó n gbára jọ di *GDP* fún ìdàgbàsókè ti dín kù, láti ìdá márùn-lé-láàádọ́ta nínú ìdá ọgọ́rùn-ún láàrin ọdún 2015, sí ìdá méjìdín-láàádọ́ta nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ní ọdún 2018. Bẹ́ẹ̀, àkójọ owó ìdókòwò ti lé sí i láti ìdá mẹ́rìnlá sí ìdá méjìdín-láàádọ́ta nínú ìdá ọgọ́rùn-ún. Bákan náà, nípa ìwòye, àpapọ̀ àwọn èròjà ìdókòwò tó n jáde lọ sí Orílẹ̀-èdè mìíràn fi hàn pé, àyípadà ìtàn rere ti n wà, lórí àwọn ohun tí ó ń fa ọwọ́ aago okòwò sẹ́yìn tẹ́lẹ̀, láti ọdún 2014.

Àmọ́, pẹ̀lú ìdúró déédé àwọn èròjà ìtukọ̀ ìdàgbàsókè ètò ọrọ̀-ajé Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà tí a n sọ̀rọ̀ bá yìí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn aṣaájú Orílẹ̀-èdè tí a gbà pé wọ́n ti tayọ nínú ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé wọn tẹ́lẹ̀, ni wọ́n tún sinmi lé ìnáwó, láti inú àsùnwọ̀n àti àgbéjáde ìlò ìnáwó, gẹ́gẹ́ bí agbára ìtẹ̀síwájú wọn.

Ìgbésókè-sódò-lójijì tàbí ohun tí a mọ̀ sí àìfara-rọ àfikún owó ọjà ti dín kù. Àìfara-rọ àfikún owó ọjà yìí ti já wálẹ̀ ní Aáfíríkà láti nnkan bí ìdá méjìlá-ó-lé-ẹyọ mẹ́fà nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ní ọdún 2017 sí ìdá mẹ́wàá-ó-lé-ẹyọ mẹ́sàn-án nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ní ọdún 2018. Bákan náà, ni a ń ṣe àfojúsùn pé kí àìfara-rọ àfikún owó ọjà náà túnbọ̀ dín kù sí ìdá méjọ-ó-lé-ẹyọ kan péré nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ní ọdún 2020. Àdìpèlé-alámì-méjì àfikún owó ọjà a máa fi igbà púpọ̀ wáyé, nígbà mìíràn, níbi tí Orílẹ̀-èdè kan sí èkejì kò bá ti fara rọ, tàbí níbi tí Orílẹ̀-èdè bá ti ń ní aáwọ̀ láàrin ara wọn. Pàápàá tí irú Orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ kì í bá ṣe ara Àjọ Orílẹ̀-èdè tí wọ́n jọ ń ná irúfẹ́ owó kan náà. Àìfara-rọ àti àfikún owó ọjà ṣégeṣège wọ́pọ̀ ní Orílẹ̀-èdè South Sudan báyìí. Lọ́wọ́lọ́wọ́ báyìí, Orílẹ̀-èdè náà ní ìmọ̀lára àìfara-rọ àti àfikún owó ọjà ṣégeṣège bí i ìdá ogún mẹ́wàá-ó-dín-méjìlá péré, nínú ìdá ọgọ́rùn-ún; nítorí àìfara-rọ àti rògbòdìyàn ètò ọrọ̀-ajé tó ń bá wọn finra.

Àìfara-rọ àfikún owó ọjà ti dín kù sí nnkan bí i ìdá méjì tàbí àìní ìdá kankan nínú ìdá ọgọ́rùn-ún. Bákan náà ni ó rí lọ́dọ̀ àwọn ènìyàn Ààrin-gbùngbùn Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà àti ní ọ̀dọ̀ àwọn Àjọ Olùdókòwò Aáfíríkà kan náà – *The African Economic and Monetary Community* àti láàrin Àjọ *West African Economic and Monetary Union.* Kódà, ní ọ̀dọ̀ àwọn Àjọ tí wọ́n jọ wà ní ibùdó kan náà, tí a mọ̀ sí *CFA,* ìdíkù ti bá àìfara-rọ àfikún owó ọjà nítórí ànfààní tí wọ́n ní sí ìlò owó Ìjọba Euro.

**Ìpò Ètò Ìsúná ti ń gbéra sọ díẹ̀ díẹ̀**

Láàrin ọdún 2016 àti 2018, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn Orílẹ̀-èdè ló gba oríyìn fún níní ìtẹ̀síwájú lórí àfikún owó ìdókòwò nípasẹ̀ ìní owó orí, (*tax revenue*), nígbà mìíràn èwè, ọ̀pọ̀ ló mú àdínkù bá ètò ìsúná wọn. Àfikún èrè yanturu jẹ́ ohun tó mú ọjà gbé owó lórí, àti ìdí tí àyípadà ìtẹ̀síwájú fi wáyé; ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn Orílẹ̀-èdè náà ló ṣe àtúngbéyẹ̀wò òfin àmúlò ìgbésẹ̀ sísan owó orí. Àwọn ònà ìkówójo láti inú ilé fún ìdàgbàsókè ti gbèrú lóòótọ́, ṣùgbọ́n kò kógó já tó, fún ìdàgbàsókè ohun tí àgbáyé nílò fún ìtẹ̀síwájú.

Lọ́wọ́lọ́wọ́ báyìí, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, gbèsè ti ń fẹjú, àwọn àsankù owó tó yẹ kí ó wà nínú àsùnwòn ajẹsẹ́kù ń bùrùjà sí í nípa àdínkù, owó tó yẹ kí ó máa rogún sínú ilé láti òde sínú àsùnwọ̀n Aáfíríkà láti mú kí àlékún èrè wọlé láti orí $170.8 bílíọ̀nù dọ́là láàrin ọdún 2016 sí $193.7 bílíọ̀nù dólà ní ọdún 2017, ní èyí tí ó dúró fún ìdá ẹlẹ́yọ méje péré nínú ìdá rẹrẹẹrẹ tí ó yẹ láti kún ẹ̀kúnwó owó tí ó n wọlé fún ìsúná *GDP* (láti inú ìdá méje-ó-lé-ẹyọ mẹ́jọ nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ní ọdún 2016 sí ìdá mẹ́jọ-ó-lé-ẹyọ márùn-ún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ní ọdún 2017).

Àwọn àsanwọlé èrè ní ìtumọ̀, bẹ́ẹ̀ ni ó sì mú ìtẹ̀síwájú tó dára bá ọrọ̀-ajé, àsẹ́sílẹ̀ ètò isúná gbèrú ní àwọn abala tí ó yẹ kí ọrọ̀-ajé ti búrẹ́kẹ́ sí i, tí ó fi jẹ́ pé a rí $69 bílíọ̀nù dọlà ní ọdún 2017; ní èyí tí ó jẹ́ bí i ìlọ́po ọ̀nà méjì iye àsúnsí ọrọ̀ ìdókòwò lọ́dún naà. Yàtọ̀ sí ìwọ̀nyí, àsúnsí owó *FDI* tó ń wọlé ti dín kù láàrin ọdún 2008. Àṣẹ́sí ìsúná owó náà já wálẹ̀ láti $58.1 bílíọ̀nù dọ́là sí ipò tí ó wà bí i ọdún mẹ́wàá sẹ́yìn; tí ẹ̀dínwó náà sì jẹ́ $41.8 bílíọ̀nù dọ́là ní ọdún 2017.

Kókó ohun tó ṣe okùnfà ìjákulẹ̀ bá ọrọ̀-ajé, àti àwọn akùdé mìíràn lórí ètò ìsúná fún àgbáyé, tó sì mú kí ìlàkàkà àtúntò-túnṣe bá ètò-ìsúná gbogbo-gbòò bayìí, kò ṣẹ̀yìn àyípadà tó bá ẹ̀kúnwó owó-nàá láàrin àwọn Orílẹ̀-èdè tó ti rẹ́sẹ̀ walẹ̀ dáadáa nínú ètò ọrọ̀-ajé àti ìdàgbàsókè ní àgbáyé.

Ìrànlọ́wọ́ Ajẹmọ́-dàgbàsókè láti ọ̀dọ̀ Ìjọba (**ODA**) lórí owó tó ń wọlé, gbéra sọ gidigidi ní ọdún 2013, tí ó fi jẹ́ pé $52 bílíọ̀nù dọ́là ni ó wọlé. Àmọ́ lẹ́yìn àkókò yìí ni ohun tí ó n ó wọlé dín kù sí $45 bílíọ̀nù dọ́là ní ọdún 2017; tí àwọn Ìpínlẹ̀ tó burú fún jù lọ sì bẹ̀rẹ̀ sí ní í gba owó ìrànlọ́wọ́ ODA náà, gẹ́gẹ́ bí ìdá *GDP* tí ó ju ti àwọn Ìpínlẹ̀ tí kò ní ìṣòro lórí ọ̀rọ̀ ìsúna ọrọ̀-ajé wọn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹkùn lo ṣe àmúlò ìjẹyọ èrè ẹ̀kúnwó owó tí fún wọn - láàrin ọdún 2005 sí ọdún 2010 àti ọdún 2011 sí 2016; Ìwọ̀-Oòrùn Aáfíríkà sì jẹ́ àwùjọ tí ó jẹ ànfààní ìrànwọ́ yìí jù lọ.

Nígbà tí àwọn gbèsè asàn-túnsan ń pọ̀ sí i ní ààrín àwọn Orílẹ̀-èdè kan ní Aáfíríkà, AjọOrílẹ̀-èdè Àgbáyé kò ní ìrírí ìṣoro gbèsè ajẹtúnjẹ bẹ́ẹ̀ rárá.

## Gbèsè Aáfíríkà ń Peléke sí i! Ṣùgbọ́n Kò sí Ìpayà lórí Àjẹtúnjẹ Gbèsè

Lẹ́yìn ọdún 2017, àkójọpọ̀ gbèsè tí Ìjọba jẹ sínú *GDP* ti tó ìdá mẹ́tà-lé-ní-àádọ́ta nínú ìdá ọgọ́rùn-ùn ní Aáfíríkà, ṣùgbọ́n ìgbésẹ̀ yìí wáyé láti ara onírúurú ìdí pàtàkì, ní èyí tí ó sì kári ọ̀pọ̀ Orílẹ̀-èdè àgbáyé. Pẹ̀lú ẹ̀rí tó dájú, tí a gbà sílẹ̀, nínú Orílẹ̀-èdè méjìlé-láàádọ́ta, tí ó jẹ gbèsè sínú agbo ìrànlọ́wọ́ *GDP*, Orílẹ̀-èdè mẹ́rìndínlógún péré nínú wọn ni gbèsè wọn dín sí ìdá ogójì; lára wọn ni : Algeria, Botswana, Burkina Faso, àti Mali. Nígbà tí àwọn Orílẹ̀-èdè mẹ́fà mìíràn: Cabo Verde, Congo, Egypt, Eritrea, Mozambique, àti Sudan sì jẹ gbèsè tí ó ju ìdá ọgọ́rùn-ùn lọ. Ìlànà àátẹ̀lé tí wọ́n ti máa ń ṣàmúlò láti mọ̀ bóyá ó rọrùn fún Orílẹ̀-èdè kan láti san gbèsè rẹ̀ fi Orílẹ̀-èdè mẹ́rìndínlógún sí ààyè ẹni tí agbára wọn kò ní í lè ká sísan gbèsè àjẹsílẹ̀ wọn. Nítorí náà, ààyè tí òrò ìsúná àti gbèsè sísan wà ní àwọn Orílẹ̀-èdè kan báyìí, fi hàn pé, a nílò láti tètè ṣèwádìí, àti àwárí ohun tí ó ń ṣe okùnfà àìkọbi-ara sí sísan owóyàá tàbí gbèsè tí wọ́n bá jẹ. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, àìlèsan gbèsè peléke sí i láàrin àwọn Orílẹ̀-èdè kan, arídájú ìwoye wà pé Orílè-èdè Àgbáyé lápapọ̀ kò sí nínú ewu ajẹtúnjẹ àti àiníí-lè-san gbèsè tí wọ́n bá jẹ.

## Àìṣe-déédé Ọ̀rọ̀-Òde ní Ipa Ọjọ́ Pípẹ́ lórí Ìdàgbàsókè

Àìṣe-déédé ọ̀rọ̀-ajé òde Aáfíríkà ti mú kí nnkan bàjẹ́ kọjá ààlà nínú ìrísí iye àsùwọ̀n méjèèjì tó jẹ́ ti ìpawó-wọlé àti ti ìdókòwò. Àṣẹ́kù gbèsè tí àsùnwọ̀n ìpawó-wọlé fi yàtọ̀ ju ìdá mẹ́rin nínú ọgọ́rùn-ún nínú *GDP* lọ; lẹ́yìn ọdún 2017 (ti àwọn ààrin (median) jẹ́ ìdá mẹ́fà-ó-lé-ẹyọ méje nínú ìdá ọgọ́rùn-ùn) àti pé, pẹ̀lú àyípadà gan an tí a sọ pé ó ti ń wà, àdínkù tí kò bójúmu ti ń wáyé láti ìgbà tí a ti wọ ọdún 2000-. Ìwọ̀nyìí lè jẹ́ kí ẹ̀rù wà fún ààyè láti ṣe ìgbèrúsókè ètò ìsúná; nítorí náà, ìwoye yìí pè fún àtúntò-túnṣe aláìjáfara àti àmójútó gidi fún ọjọ́ iwájú.

Pẹ̀lú òfin òdìwọ̀n ìṣewẹ́kú-ètò owó sísan (tí ó sọ pé, owó ọ̀rọ̀-ajé òde tí a fi ń dí àlàfo tí ó lè fẹ́ yọ sílẹ̀ lórí ọ̀rọ̀ ètò ìsùná, àṣẹ́kù náà gbọdọ̀ máa padà sí ààyè rẹ̀, bí i ọ̀pọ̀ tí yóò wà fún ìlò ọjọ́ iwájú; láti lè dínà mọ́ àìní; pàápàá, nígbà tí a bá fẹ́ ṣe àmúlò àṣẹ́kù ọ̀pọ̀ náà, kí ó lè ba à lọ dínà mọ́ ìyàn, àti láti fi dí àlàfo ọ̀dá owó lẹ́nu). Gbèsè tí Aáfíríka jẹ gẹ́gẹ́ bí àfihàn inú àsùnwọ̀n owó òde, ṣe é wá ìdí abájọ fún, bí wọ́n bá pọn ọ̀pọ̀lọpọ̀ omi sílẹ̀ de òngbẹ ọjọ́ iwájú. Ibi tí ọ̀rọ̀ yóò já sí nìyí, níwọ̀n ìgbà tí àkójáde ọjà fún ìdókòwò tí ó ń bọ̀ sí òde bá ti ń ṣe déédé, ní ìbámu pẹ̀lú òfin àlàkalẹ̀, tí ó sì ní àsomọ́ pẹ̀lú ìgbèrùú-sókè owó ìdókòwò, ìpèsè ọjà àti irúfẹ́ àwọn ilé-iṣẹ́ ìdókòwò tí yóò fi kún agbára àṣegbèrùú nínú ipò iyì tí wọ́n wà káàkiri àgbáyé, ní èyí tí yóò sì lè mú wọn máa tẹ̀síwájú nínú sísan àwọn gbèsè àjesílẹ̀ òde wọn déédé.

## Àwọn Ewu Ìwòye Ìrísí

Àwọn ewu tí ó yí àsọtẹ́lẹ̀ ìwòye àfojúsùn ọ̀rọ̀-ajé Aáfíríkà ká kò lónkà.

Lákọ̀ọ́kọ́ ná, ìgbérùú nínú ìpayà lórí ìdókòwò láàrin Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà àti àwọn alájọdókòwò wọn, yóò fa àdínkù bá ìdàgbàsókè ọ̀rọ̀-ajé lágbàáyé, pẹ̀lú ipa tí àyọrísí rẹ̀ kò dára fún Aáfíríkà. Ipa tí ìpayà tí a ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí ní, pẹ̀lú agbára tí owónàá Dọ́lá ilẹ̀ Amẹ́ríkà ń gbà sí i lágbàáyé, ti jẹ́ kí àìṣe déédé owó ọjà ga sí i, débi pé, owó ọjà àti owónàá àwọn Orílẹ̀-èdè yòókù tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ n dìde sókè, ti fẹ́rẹ̀ kógbá sílẹ̀.

Bí ìṣọwọ́-bèère ọjà lágbàáyé bá fà sẹ́yìn, owó ọjà náà lè dín kù, tí ó fi jẹ́ pé, àdínkù yóò bá ìtẹ̀síwájú *GDP*, bẹ́ẹ̀ yóò ní ipa gidi lórí okòwò, àti àṣẹ́kù ìsúná fún àwọnònṣòwò òde Orílẹ̀-èdè ilẹ̀ Aáfíríkà.

Lọ́nà kejì ẹ̀wẹ̀, iye owónàá ìṣúná òde tún lè jẹ́ ohun tí yóò gbẹ́nu sókè sí i, pàápàá bí àfikun owó ọjà bá tètè ní ẹ̀kúnwó, ní àwọn Orílẹ̀-èdè tí wọ́n ti gbèrùúsókè dáadáa, tí wọ́n sì ti gbéra kánkán ju àwọn yòókù lọ.

Lọ́nà kẹta, bí ìmọ̀lára ojú-ọjọ́ bá tún ní ipa tí kò dára lórí Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà nípasẹ̀ àyípadà tí ó n bá ojú-ọjọ́ gẹ́gẹ́ bí ó ti n ṣẹlẹ̀ ní ẹnu odún díẹ̀ sẹ́yìn báyìí, ó ṣe é ṣe kí àwọn irè oko ọ̀gbìn àti ìdàgbàsókè èrè *GDP* ní ìfàsẹ́yìn ju bí a ti wòyè lọ.

Lọ́nà kẹrin ẹ̀wẹ̀, àìṣedéédé ọ̀rọ̀ ìṣèlú àti ọ̀rọ̀ ààbò tí ó mẹ́hẹ ní àwọn apá ibì kan, lè fa àkùdé ìgbèrúsókè bá ọ̀rọ̀-ajé. Àwọn Orílẹ̀-èdè tí ó bá ti ní àyípadà rere lórí ọ̀rọ̀ ìsúná àti ọ̀rọ̀ ọjà-òde, tí wọn kò sì ní gbèsè àjẹsílẹ̀ rẹpẹtẹ ni yóò ní agbára láti lè kojú ìyàlẹ́nu tí wọ́n bá rí. Ṣùgbọ́n fún àwọn tí kò bá tí ì ṣe àtúnṣe ríró tò ìṣúná àti owónàá wọn lágbára, yóò kojú ìrírí ìjákulẹ̀ gidigidi.

## Ètò Ìṣúná Aládàpọ̀-kan náà máa ń fa Ọ̀pọ̀lọpọ̀ Ìṣòrò

Gẹ́gẹ́ bí ìwòye àfojúsùn ìtọ́kasí tí a ṣe lọ́dún tí ó kọjá, àwọn Orílẹ̀-èdè ń kópa nínú ṣíṣe ẹgbẹ́ alájọfowó-dókòwò pẹ̀lú ète ìṣúná ọlọ́pọ̀ ìhun ànfààní. Ìhun ànfààní náà ní í ṣe pẹ̀lú ìṣedéédé iye ìpàarọ̀ owó àti ètò ìṣúná láyìíká, ní èyí tí yóò sì mú àdínkù bá owó (gbèsè) òde, ọ̀pọ̀ ànfààní nípasẹ̀ ìdókòwò láàrin agbègbè sí agbègbè, ọ̀pọ̀ ìṣúná tí ó kó àkóyawọ́ èrò lórí aládàpọ̀-kan náà, tí owó orí ọjà bẹ́ẹ̀ kò sì gunpá ju owó ìdókòwò ọjà náà lọ, (pàápàá nígbà tí iye owó orí ọjà bá kùnà), àti nígbà tí ó bá tún gbèrùú, ní ìṣewẹ́kú láàrin àwọn Orílẹ̀-èdè yòókù. Àmọ́, ti owó orí ọjà náà tún wà níbẹ̀. Nínú oríkì tí a lè fún ìgbésẹ̀ náà, ìwọ̀nba ààyè ni ẹgbẹ́ alájọfowó-dókòwò ní, nínú ẹgbẹ́ àjọ Orílẹ̀-èdè láti lo èròjà ìṣúná owó láti ṣe àtúnṣe àyípadà tó yẹ sí ìpàyà òde.

Èrènjẹ ànfààní tí ó wà nínú ìṣúná aládàpọ̀-kan náà fún ilẹ̀ Aáfíríkà jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn ète ìdókòwò alágbègbè àti àsopọ̀ gbogbo-gbòò lágbàáyé; àmọ́, ìrísí ìmọ̀lára rẹ̀ nira púpọ̀ láti rí i gbá mú. Bákan náà ni pé, ìṣòro tí ó rọ̀ mọ́ ètò ìṣúná ọrọ̀-ajé pọ̀ púpọ̀ ju àwọn àlàyé àtúpalẹ̀ àfojúsùn tí ó hànde.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìlànà àgbékalẹ̀ tí ó bójúmu, tí àwọn onímọ̀ ètò ìṣúná/ọrọ̀-ajé máa ń ṣàmúlò bí i (*ọ̀nà ìrọ̀rùn owónàà àyíká/agbègbè*) - *(the optimal currency area)* lè jẹ́ ìlànà tí ó nira púpọ̀ láti fi òntẹ̀ lù fún àwọn Orílẹ̀-èdè tí ó jẹ́ pé wọn kò fi bẹ́ẹ̀ ní gbèdéke ẹ̀rí àrídìmú lórí àwọn àìbáramu kọ́kọ́rọ́ tí ó sí ètò ìṣúná/ọrọ̀-ajé. Kò dájú pé àwọn àìdọ́gba inú ọjà àgbáyé láàrin àwọn ọ̀ṣìṣẹ́ lè tètè kásẹ̀ nílẹ̀. Bákan náà, kò dájú pé ìjàyà lè ní ipa lórí ẹnì kan nínú àjọ egbé olùdókòwò aládàpọ̀-kan náà, kí ó má kan àwọn yòókù. Ọ̀rọ̀ náà yóò dà bí i, òwe Yorùbá tí ó sọ pé, ohun tí ó ń ṣe abọ́yadé, gbogbo ọlọ́ya ni ó ń ṣe ni. Nítorí náà, kò sí àrídájú pé Àjọ aláṣẹ Aáfíríkà lÁgbàáyé yóò ní agbára tó bí ó ṣe yẹ fún ìrànlọ́wọ́, tí ó kún ojú òsùnwọ̀n fún àtìlẹ́yìn àwọn Orílẹ̀-èdè tí ó bá ní ìṣòrò ìjákulẹ̀ nípasẹ̀ ètò ọrọ̀ ìṣúná wọn.

Fún àwọn Orílẹ̀-èdè tí wọ́n wà nínú ajọ ìdókówò àdàpọ̀-kan náà, tí wọ́n sì ń ṣe dáadáa, àgbékalẹ̀ òfin kan, tí ó jẹ́ káríayé-kárí Orílẹ̀-èdè, fún àwọn tí wọ́n bá jọ ń sowọ́pọ̀ gbọdọ̀ wà; tí yóò sì máa ṣe àmójútó fún ìrànlọ́wọ́ àwọn ẹgbẹ́ inú àjọ yìí, lórí ọ̀rọ̀ ìṣòrò àìròtì, tí ó sì lè yanjú ìjayà òjijì tí wọ́n bá ní. Ìfààyè-gbàni láti ṣe bí ó ṣe wuni, ká rìn-ká yan fanda fún àwọn òṣìṣẹ́, owó ìdókòwò àti àgbékiri ọjà fún títà, yẹ kí ó jẹ́ ohun tí ó ṣe é ṣe, láìní ẹ̀tàn nínú - kì í ṣe ètè tàbí èròngbà lásán.

Òfin tó rọ̀ mọ́ gbèsè àti àìnító, gbọdọ̀ wà ní ìlànà tí ó mú ìṣedéédé dání. Èyí sì gbọdọ̀ jẹ́ káríayé-kárí-gbogbo àwọn ẹgbẹ́/àjọ, kí àmójútó tí ó péye sì wà láti ọ̀dọ̀ àwọn tí àṣẹ wọn múlẹ̀ dáradára. Bákan náà, àwọn àjọ elétò ìṣúná àti ilé ìfówópamọ́ gbọdọ̀ wà lábẹ́ àmójútó, tí ó kún ojú òsùnwọ̀n, lábẹ́ àṣẹ àjọ àgbáyé, tí kò rọ̀gbọ̀kú lé lílo èèkù ìdà nígbà tí ó bá wù ú fún àmójútó òfin ajẹmọ́-níná owó láìná ìná àpà. Ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn àfojúsùn mẹ́rẹ̀ẹ̀rin yìí ni ó yi tíkẹ́ bí ẹran námọ̀ láti mú ṣe. Lápapọ̀, wọ́n ṣe àfihàn iṣẹ́ ńlá fún àmúṣe láti dojú kọ ìṣòro ọrọ̀-ajé/ètò ìsúná káríayé tí ó kó àkóyawọ́ gidi.

Àfojúsùn fún ìdàgbàsókè onídàá mẹ́rin nínú ọgọ́rùn-ún ní ọdún 2019 àti ìdá mẹ́rin-ó-lé-ẹyọ kan fún ọdún 2020 jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà tí a ń ṣiṣẹ́ lé lórí.

### Àwọn Òníruúru Ìtumọ̀ Ìlànà Àgbékalẹ̀ Òfin

Àtúnsọjí ìdàgbàsókè àníṣékù ọrọ̀-ajé Aáfíríkà *GDP* láti inú ìnira ọdún 2016 ṣe àfihàn ipa taakun taakun láti kọ ìyà àti àìnító tí ó n mú ìpayà òjijì bá àwon agbègbè àti àgbáyé, pààpàá ipa tí ìpayà náà mú bá wọn. Àfojúsùn fún ìdàgbàsókè onídàá mẹ́rin nínú ọgọ́rùn-ún ní ọdún 2019 àti ìdá mẹ́rin-ó-lé-ẹyọ kan fún ọdún 2020 jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà tí a ń ṣiṣẹ́ lé lórí.

Àmọ́, ọ̀pọ̀ nínú àwọn tí wọ́n gbáralé kíkó ọjà jáde kí wọ́n tó lè mú ìdàgbàsókè bá ọrọ̀-ajé wọn, àti kí wọ́n tó lè bọ́ nínú oko gbèsè, láti bọ́ nínú wàhálà iye owó ọjà, ti fa ọ̀pọ̀ ìdíwọ́ bá ọrọ̀-ajé Aáfíríkà láti ipasẹ̀ ìdàgbàsókè tí ó ga fún ìdúró sinsin ọrọ̀-ajé náà. Àwọn tí wọ́n sì sinmi lé ìṣòwò ọjà kéékèèkéé náà ti ṣe àdínkù ọrọ̀-ajé alákòoyawọ́ káríayé gẹ́gẹ́ bí òdiwọ̀n onígbèé-léwọ̀n kan, tí ó mú ìpayà dání, bákan náà ni ètò ìfọjà-dí-ọjà láàrin ìlànà tí ó lè mú ìdàgbàsókè àti ìdúró-sinsin òfin àlàkalẹ̀ dání. Nípasẹ̀ báyìí, àti gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe máa ń ṣe àtẹnumọ́ – Aáfíriká nílò àtúnṣe gidi fún àṣeyọrí, láti lè ṣe àyípadà ìhun òòró àti ìbú tí ó yẹ nínú ètò ọrọ̀-aje àti ìsúná wọn.

Yàtọ̀ sí owó tí ó ń wọlé láti ipasẹ̀ àwọn ilé-iṣẹ́ kan, bí i owó-orí àti ọ̀nà ẹ̀sún mìíràn, ọ̀pọ̀ Orílẹ̀-

Láìsí àní àní, gbígbòòrò nínú ṣíṣe ọ̀pọ̀ òwò tí ó lè mú àyípadà àti ìhun amúdàgbàsókè bá ètò ìsúnà ṣe pàtàkì fún ètò ìsúná. èdè Aáfíríkà ni ó ti ń gba àgbàlé owó ìrànwọ́ *ODA* àti *FDI* —ní èyí tí kò sì pẹ̀lú owó tí wọ́n ń dá padà, àti láìfi èyí tí wọ́n bá máa gbà padà lọ́nà tí kò bófin mu, àti lọ́nà mìíràn.

Àgbékalẹ̀ òfin àtẹ̀lé láti mú ìdínkù bá iye tí a ó máa ṣetò àmúránṣẹ́ owó àti ọ̀nà láti mú ìtẹ̀síwájú bá ojú òpó náà, gbọdọ̀ wà fún àwọn olókoòwò tí ó ń gbé òkèèrè; bákan náà ni ìpèsè àwọn ohun amóríyáni mìíràn lè jẹ́ kí ọ̀nà àbáyọ wà fún ṣíṣe ètò alámùúgbòòrò fún yíyanjú ìṣorò ìnáwó tí kò fààyè gba ìtẹ̀síwájú.

Ìlànà ìrọ̀rùn fún fífi owó ránṣẹ́ àti dídáwó-padà láàrin Àwa-ra-wa lÁáfíríkà kò sí tó, ìdí nìyìí tí àwọn ènìyàn fi n lo ọ̀nà àìtọ́, nípasẹ̀ bẹ́ẹ̀, fífi owó ránṣẹ́ sí òkèèrè wọ́n gọbọi. Bákan náà, ìwọ̀nba pérété ni ilé-ìfowópamọ́ tí ó wà fún ìlànà yìí nínú Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà, ní èyí tí ipa rẹ̀ sì ń fa ìdíwọ́ fún ìfowóránṣẹ́ àti ètò ìdáwó-padà bí ó ṣe yẹ.

Lóòótọ́ ni pé Aáfíríkà ti gboríyìn nípasẹ̀ àlùjá ọ̀nà kan gbòògì, tí ó yára jù lọ fún ìdàgbàsókè, tí ó sì ṣe é fọkàn tán láti nnkan bí i ọ̀rúndún ọdún méjì sẹ́yìn, àmọ́, ìdàgbàsókè náà kò tí ì bí pípèsè iṣẹ́ bí ó ṣe yẹ!

Gbígbé owó ránṣẹ́ jáde káàkiri lọ́nà àìtọ́ ń pa ọ̀pọ̀lọpọ̀ Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà lára, ó sì tún ń ṣe ìfàsẹ́yìn bá abala ibi tí ó yẹ kí àmúgbòòrò ètò ìnáwó fún okòwò lórí ìpèsè àwọn ohun amáyérọrùn, bí i iná ẹ̀lẹ́tíríìkì, àti àwọn iṣẹ́ àkànṣe ọlọ́jọ́-pípẹ́ mìíràn wà. (Àwọn àsùnwọ̀n owó onípasípayọ tí owó ń gbà jáde lọ́nà àìtọ́ jẹ́ ìdá márùn-ún-lé- márùn-ún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ètò àpapọ̀ èrènjẹ tí *GDP* ní fún àwọn ará agbègbè Saharan Aáfíríkà, bẹ́ẹ̀ ó ní ipa tí ó tó iye mílíọ̀nù owó Dọ́là kan-ó-lé-méjọ ẹgbẹ̀lẹ́gbẹ̀ tírílíọ̀nù ($1–$1.8) láti bí i àádọ́ta ọdún sẹ́yìn.) Bákan náà, yóò nílò kí àmójútó gidi wà láti mọ bí nnkan ṣe n ló sí, lórí ọ̀rọ̀ gbèsè ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn agbègbè ilẹ̀ Aáfíríkà tí ètò iṣúná/ ọrọ̀-ajé wọn ti méhẹ; pàápàá, ní àwọn ilẹ̀ Aáfíríkà tí wọ́n ti nílò ìdàgbàsókè. Títètè ṣe àmójútó ọrọ̀-ajé wọn àti gbígbọ́ etí ẹ̀yìn, yóò fún wọn ní ànfààní láti pàkíyèsí sí ohun tí ó bá yẹ, kí gbèsè tó wọ̀ wọ́n lọ́rùn jìnnà.

Ní àfikún, ó yẹ láti ṣe ìfitónilétí pàtàkì nípa mímú ojú tó owóyàá tàbí sísan gbèsè fún àwọn ènìyàn, pàápàá láàrin àwọn olósèlú ìjọba ní ìpele tí ó ga, láti ṣe àfilọ́lẹ̀ àjọ kan fún àmójútó ṣíṣe déédé nínú ìlò àwọn ohun tí ó ti wà tẹ́lẹ̀; láti dínà àjẹkún gbèsè àti láti fi agbára kún àwọn Orílẹ̀-èdè tí wọn kò lè dá san owóyàá wọn gẹ́gẹ́ bí gbèsè òde, fún ìrànlọ́wọ́ láti lè gbèrùú kúrò nínú ìlò gbèsè àti dídìde láti gbé ètò ìsúná wọn ró.

Bí èlé orí owó ti n bọ̀ sípò ní lọ́ọ̀lọ́ọ̀ yìí, láàrin àwọn Orílẹ̀-èdè tí wọ́n ti búrẹ́kẹ́ nínú ètò ọrọ̀-ajé wọn, àti bí iye ìdápadà èlé owó tí ó n wọ Aáfíríkà ti n dín kù báyìí, òfin ìlànà àtẹ̀lé náà gbọdọ̀ yípadà, tí ó fi jẹ́ pé, ààyè àti báni-dókòwòpọ̀ yóò ní ẹwù nínú, ti àwọn olókoòwò yóò sì fi bẹ̀rẹ̀ sí ní í wá sí àwọn agbègbè àti ìletò nípasẹ̀ àyípadà rere tó wúnilórí tí wọ́n bá n rí, pẹ̀lú ìṣesí ọrọ̀-ajé tí ó ti tàn káríayé, bí I ìgbèrùúsókè èrè lórí àsùwọ̀n *GDP*, wíwà lójú kan iye owó ọjà àti wíwálẹ̀ ọjà, tí kò sì máa jó lọ-jó-bọ̀ bí ìlẹ̀kẹ̀ ìdí ní gbogbo ìgbà, àti ààbò tí ó péye lórí dúkìá àwọn ènìyàn. Ọ̀nà kan pàtàkì lati ṣe àrígbámú okòwò tí ó mú ìdàgbàsókè wọlé nípasẹ̀ àkójáde ọjà lọ sí òkèèrè, ni láti ní ẹ̀rí okòwò alárìígbámú-fojúrí àti láti ṣe àfikún ìpèsè àwọn ohun ọrọ̀-ajé lọ́tun tí ó ṣe é rí wò.

Ìwọ̀núbọ̀nú òfin àtẹ̀lé tí ó dojúkọ àfikún ìpín tí kò jìnnà jù, àti ojú-owó ìdókòwò ọjà alákòójáde-tà, lè ṣiṣẹ́ ìrànlọ́wọ́ fún àwọn Orílẹ̀-èdè láti jẹ ànfààní láti ara òwò kéékèèkéé àti okòwò-ọlọ́rọ̀-ajé tí ó fẹjú, àti láti ṣe àwújáde ìmọ̀ tí ó ṣe e fi ṣọwọ́ láti ibùdó ìmọ̀ kan, tí ó ga fún ìgbésẹ̀ ìpèsè tí ó ti fẹjú ju ipele kékeré lọ.

- Àwọn ìpele ìdókòwò aládàáni kan wà tí ó ní àfojúsùn pẹ̀lú ìdàgbàsókè ọjọ́ iwájú, fún ìṣedéédé okòwò ṣíṣe. Àwọn Orílẹ̀-èdè lè tipasẹ̀ ìtẹ̀síwájú tí ó dé bá àyípadà gbèsè òde se àmúdúró fún owóyàá tí ó gbòòrò, níwọ̀n ìgbà tí owó-orí sísan, òté òsùnwọ̀n àwọn àjọ fún ìdókòwò, àti bí ìpèsè àwọn ohun amáyérọrùn bá ti wà ní ṣẹpẹ́, láti wa ọkọ̀ àwọn abala kọ̀ọ̀kan wọ̀nyìí:
- láti lè ṣe àwàgúnlẹ̀ okòwò tó dúró déédé fún ìbojúwẹ̀yìn tí ó yẹ. Ṣíṣe àtẹnumọ́ irúfẹ́ ibùdó tó bágbàmu fún ìpèsè ohun amáyédẹ̀rùn rere, tí yóò bù kún ìní okòwò láti ipasẹ̀ ìsọdọ̀tun agbègbè fún ọjà títà alákòó-jáde-ròkè-òkun, tí a ó sì lè ka àwọn ibùdó bẹ́ẹ̀ kún ti àgbáyé, pẹ̀lú pé ó tí ní àwọn kọ́kọ́rọ́ aṣọdìwọ̀n ìpèsè ìdàgbàsókè.
- Lára ohun àkàkún àwọn Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà ni àkọsílẹ̀ ọjà alákòó-jáde-ròkè-òkun, àyípadà rere fún èlé owó orí ọjà tí ó ń wá láti òde, tí ìhun rẹ̀ sì wà láti mójú tó ìṣoro tí ó lè yọjú láàrin ọ̀nà àti àwọn ọjà tí ó ń mú owó wọlé, tí òhun náà sì ní òfin àtẹ̀lé pàtàkì láti mójútó pẹ̀lú àlúpọ̀ ọjà nnkan ìlò sí ọjà aládàá-ńlá fún owò ńlá. onítẹ̀síwájú ìhun fún kíkó ọjà òkèère

wọlé, abala kan tí ó ń ṣiṣẹ́ lórí àyípadà .

- Ṣíṣe àmójútó àdàpọ̀-òwò kan náà tí yóò le mú wa wà ní ojútáyé àgbáyé, nípasẹ̀ àfikún, àti ànfàání alásopọ̀ tí ó gbé iṣẹ́ owó aláyànṣe dání, àti òdiwọ̀n fún òṣìṣẹ́, láti fi agbára kún agbára wọn ní agbègbè, láti fààyè gba àwọn Orílẹ̀-èdè yòókù láti gberí sókè nínú okòwò wọn, kí àwọn tí ó ti n gbìyànjú láti gòkè nínú ètò ìṣúná wọn fún ìdámọ̀ iṣẹ́ kan ní pàtó, àti láti ṣe àtúnṣe sí àwọn onírúúrú àìdégba ara iṣe òde.
- Ṣíṣe àtúnná àwọn èlé owó ọjà láti inú àṣẹ́sílẹ̀ èrè sí ojú-nàá àwọn abala tí ètò ìsúná àwọn kan tí ọ̀rọ̀ wọn ti gbọ̀rẹ̀gẹ̀jigẹ̀ nínú ìpèsè èròjà fún ìdàgbàsókè àti àwọn ọ̀nà mìíràn, tí ó lè mú kí àṣepọ̀-dòwòpọ̀ wà pẹ̀lú ète láti mú kí àwọn ànfàání àgbáyé nípasẹ̀ mímú òwò ṣíṣé gẹ́gẹ́ bí i igun ihun kan ṣe pàtàkì fún àyípadà ní Aáfíríkà.

## ÌPÈSÈ IṢẸ, ÌDÀGBÀSÓKÈ ÀTI ILÉ-IṢẸ́ TÓ FẸSẸMÚLẸ̀

### Pípèsè Iṣẹ́ lọ́tun láwọn Abala tí Ẹ̀rí Ìtẹ̀síwájú Àlùyọ ti Farahàn

Àfojúsùn iye ọjọ́ orí tí àwọn ènìyàn Aáfíríkà tó lápapọ̀ gẹ́gẹ́ bí ìwòye, yẹ kí ó lé sí i láti mílíọ̀nù 705 ní ọdún 2018 sí bí i bílíọ̀nù 1.0 ní ọdún 2030. Bí omilẹgbẹ mílíọ̀nù àwọn ọ̀dọ́ ṣe ń darapọ̀ mọ́ òde ayé láti wá ounjẹ òòjọ́ wọn lọ́jà àgbáyé, bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀rù àtipèsè iṣẹ́ gidi fún wọn ń peléke sí i. Ní ibi tí ọ̀pọ̀ àwọn èrò wọ̀nyìí dé dúró lọ́wọ̀lọ́wọ̀, Aáfíríkà nílò láti máa pèsè iṣẹ́ tuntun fún àwọn ènìyàn mílíọ̀nù méjìlá lọ́dọọdún, láti dí àìríṣẹ́-ṣe lẹ́nu, àti kí àìríṣẹ́ ó má ba à máa ràn mọ̀ ọ̀n bí iná ọyẹ́; bákan náà, ni láti tún mú ìdàgbàsókè tí ó máa tẹ ètò ọrọ̀-ajé síwájú lójúnà àtipèsè iṣẹ́; àmọ́, ìwọ̀nyí náà kò tí ì kún tó. Ìwòye wa ni pé orísun àti irúfẹ́ ìdàgbàsókè tí a fẹ́ mú wọ̀ àwujọ kan ṣe pàtàkì fún àkíyèsí.

Aáfíríkà ti ní ẹ̀rí àlùyọ nípasẹ̀ ọ̀nà kan tó yára jù lọ láti fẹsẹ̀ ìdàgbàsókè múlẹ̀ gidigidi, láti bí i nnkan ọ̀rúndún méjì sẹ́yìn; síbẹ̀, ìdàgbàsókè tó pè fún rírí-ṣẹ́-ṣè kò tí ì sí bí ó ṣe yẹ.

Ẹyọ ìdá kan péré nínú ìdá ọgọ́rùn-ún tí èrènjẹ – *GDP*- fi gbèrùú kọjá ìwọ̀n ọgọ́rùn-ún láàrin ọdún 2000 sí 2014 ní nnkan láti ṣe pẹ̀lú ìdá ẹyọ mọ́kànlé-lógójì (0.41) peré, nínú ìdá ọgọ́rùn-ún fún ìpèsè iṣẹ́ tí ó túmọ̀ sí pé ìpèsè iṣẹ́ jẹ́ ẹyọ ìdá kan-ó-lé-ẹyọ méjọ (1.8) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún péré, nínú ọdun kan, tí ó fi hàn pé ó jìnnà sí ìdá mẹ́ta nínú ìdá ohun tí ó yẹ kí ó máa jẹ́ ìpèsè iṣẹ́ olọ́dọdún. Bí irú ìgbésẹ̀ yìí bá tẹ̀ síwájú, ẹgbẹ̀lẹ́gbẹ̀ ọgọ́rùn-ún mílíọ̀nù ènìyàn ni yóò wà ní ẹgbẹ́ aláìníṣẹ́ ní Aáfíríkà nígbà tí yóò fi di ọdún 2030. Làìsí àyípadà oníhun rere, tí ó ń mú ànfàání wá fún àwọn ènìyàn àwùjọ, ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ tí wọn bá dá sílẹ̀ lè má bọ́ sí ààyè tí yóò ti wúlò fún àwọn tí wọn pète iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ fún; pàápàá níbi tí àlùyọ àti owó-oṣù bá ti kéré, tí kò sì sí ààbò tó péye lórí iṣẹ́-ṣíṣe, ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀ máa mú kí ààyè láti dójú ti ìṣẹ́ àti òṣì nira púpọ̀ ní ọdún 2030.

Ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn ohun àmúyẹ fún ọjà òṣìṣẹ́ ní Aáfíríkà ni ìgbélẹ́wọ̀n tí ó ń ga sí i nígbà gbogbo, pẹ̀lú àìpèsè iṣẹ́ síbi tó yẹ, àmọ́ tó jẹ́ pé ìpèsè iṣẹ́ aládàmọ̀dì, tí kì í ṣe irú ìpèsè ààyè tó yẹ ìdàgbàsókè àwùjọ ni ó ń hànde, èyí sì jẹ́ ìpàarọ̀ tí kò bójúmu fún ọ̀pọ̀ àwùjọ tí ó ń gbòòrò ní ọjà òṣìṣẹ́.

Bí a bá wó ò dára dára, ìwoye wa ni pé, àwọn Orílẹ̀-èdè tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń dìde nílẹ̀ nípasẹ̀ ọrọ̀-ajé gan an ni wọ́n ń pèsè iṣẹ́-sáré-ṣe-é, tí kì í ṣe ìpèsè iṣẹ́ gidi gan an lọ́nà tí ó yẹ bí i ti àwọn Orílẹ̀-èdè tí wọ́n ti gbèrú ṣaájú. Nígbà tí a ní àkọsílẹ̀ lorí àwọn iṣẹ́-sáré-n-bájà bẹ́ẹ̀, òye wa ni pé irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ kì í ní òté gidi kan dà bí alárà. Bákan náà, ó hàn gbangba pé Aáfíírikà ni ó ní ìgbélẹ́wọ̀n tí ó ga jù lọ nínú àwọn Orílẹ̀-èdè tí ó n pèsè iṣẹ́ tí ó n bọ́ sí ààyè tí kì í ṣe ibi tí ó tó lọ gbà lágbàáyé. Ìpín ìdá-méjì-lé-láàádọ́rin nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ìpèsè iṣẹ́ aláìjẹ-mọ́ṣẹ́-àgbẹ̀, bákan náà, ìfarahàn irúfẹ́ ìpèsè iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ hànde ní ìpín ìdá àádọ́rùn-ún ní àwọn Orílẹ̀-èdè mìíràn.

Síwájú sí i, kò sí ẹ̀rí àrídìmú kankan pé àdínkù ń bá à n ìpèsè iṣẹ́-sáré-n-bájà bẹ́ẹ̀ ní Aáfíríkà rárá. Bákan náà, ẹ̀rí tó dájú farahàn pé àwọn Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà mìíràn tí wọ́n sẹ̀sẹ̀ n dìde nínú ètò ọ̀rọ̀-ajé wọn ti ń ní àyípadà rere lórí ọ̀rọ̀ ìtẹ̀síwájú nínú ìhun ọjà àgbáye àwọn òṣìṣẹ́. Aáfíríkà ní ìpín tó pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ ní ọjà àgbáye àwọn òṣìṣẹ́. Ìgbésẹ̀ ìpín yẹ́lẹyẹ̀le ní ọjà àgbáye yìí ṣe é ṣe kí ó ṣe agbára, ìmọ̀ onítẹ̀síwájú fún wọn. okùnfà àmúwá òfin àtẹ̀lé fún ètò ọ̀rọ̀-ajé, tí ó máa fa àyídà fún ìpèsè ọjà àwọn òṣìṣẹ́, ìfagagbága aládàáni, nínú ìdáwọ́lé wọn, àti ìpèsè, ètò aláfikun- olórogún òwò láyìíká fún àwọn olókoòwò .

## Ìdàgbàsókè Onígbèésẹ̀ Kán-mọ́-kán-mọ́ àti Ìgbèrùúsókè Iṣẹ́

Ìdàgbàsókè onígbèésẹ̀ Kán-mọ́-kán-mọ́ tàbí ti ìdìde ọrọ̀-ajé lọ́pọ̀ ìgbà máa ń jẹ́ èyí tí àyípadà ìhun rẹ̀ mú àyípadà rere bá ìdàgbàsókè àwọn nnkan àrídìmú-yangàn láwújọ dání. Ní Aáfíríkà, ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé onígbà pipẹ́ yóò ní nnkan láti ṣe pẹ̀lú onírúurú ìṣesí àwọn ìgbèrùúsókè tó dára. Ìpèsè iṣẹ́ ní àwọn abala kọ̀ọ̀kan ìpín òsìṣẹ́ tó wà káàkiri, fún àtúnpín àwọn ìtẹ̀síwájú tí ó mú ìpín ìhun àyípadà rere bá àwọn ènìyàn ní ìrísí, àti ìdàgbàsókè ni pàtàkì abala òfin tí a ń sọ yìí.

Ní Aáfíríkà, ìdàgbàsókè onígbèésẹ̀ Kán-mọ́-kán-mọ́ so mọ́ àwọn ìrísí àtúnpín ìhun iṣẹ́, tí ìpín ìṣe rẹ̀ jẹ́ ìpín méjìdínlógún ninú ìpín àti ìpín mẹ́rìndínlógún nínú ogún ìdásílẹ̀ àwọn Ilé-Iṣẹ́. Ẹ̀wẹ̀, nínú ìpèsè iṣẹ́ tí ó mú ìtẹ̀síwájú bá ìṣe ìdásílẹ̀ àwọn ìlé-iṣẹ́ wọ̀nyìí, méje jẹ́ alábùdá ìdàgbàsókè ìpèsè iṣẹ́ tó ga nípasẹ̀ ìpín ìgbanisíṣẹ́ sí àwọn ilé-iṣẹ́ ju ṣíṣe ìsin-ni-lẹ́nu irúfẹ́ iṣẹ́ mìíràn lọ. Ìṣẹ̀lẹ̀ Ìdàgbàsókè Onígbèésẹ̀ kán-mọ́-kán-mọ́ tún jẹ́ iṣẹ́ tí ó so mọ́ ìpín mẹ́wàá nínú ìpín ogún ìdìde ìpèsè iṣẹ́ ní abala ìwakùsà ọrọ̀ àlùmọ́nì-abẹ́ ilẹ̀, àti láti ṣe àrídájú irúfẹ́ ojúṣe kan ní pàtó, fún àwọn abala ìpèsè iṣẹ́ tí a bá ṣe àfàyọ wọn ní Aáfíríkà.

Àwòtán ìrísí náà fihàn pé ìwáléra èrò bẹ́ẹ̀ ṣe déédé pẹ̀lú ète ìdàgbàsókè oníṣẹ̀lẹ̀ kán-mọ́-kán-mọ́ tí ó ní nnkan ṣe ẹ̀lú àyípadà ìhun ààtò rere.

Ìdásílẹ̀ Ilé-Iṣẹ́ tó mú ìgbésẹ̀ ìdàgbàsókè oníṣẹ̀lẹ̀ kán-mọ́-kán-mọ́ dání máa ń mú àfikún ìṣe bá gbogbo ìdàgbàsókè tí ó dára, tí ó sì ní ìtẹ̀síwájú bá ìpèsè iṣẹ́ ọjọ́-iwáju tí ó gbòòrò, a tún máa ní ipa lórí ṣíṣe àfikún agbára iṣẹ́ tí kò dúró rigidi sí ojú kan pẹ̀lù ìwọ̀n tí ó tó ìdá ẹyọ mẹ́tàdínlógún nínú ìdá náà tàbí (ìdá mẹ́ta nínú ọgọ́rùn-ún) —tí ó já sí ìwọ̀n ẹ̀ẹ̀mẹ́ta ní gíga ju ipa tí iṣẹ́-àdáṣe-sin-ni yóò ní, nínú àwọn ìṣe yòókù. Pàápàá tí Ilé-Iṣẹ́ amúdàgbà-sókè oníṣẹ̀lẹ̀ kán-mọ́-kán-mọ́ dání máa ń ní ipa ọwọ́jà ìṣe tí ó tóbi, tí ó sì kárí àwọn abala tí ó fẹjú gidi.

Ìdá (0.034) ẹyọ mẹ́rìnlélógbọ̀n nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ìwọ̀n ní ó fi tóbi ju ìpèsè iṣẹ́ tí ó mú ìgbèrùú alàìdúró-rigidi dání fún àdásílẹ̀ Ilé-Iṣẹ́, ẹyọ ìdá méjìdínlọ́gbọ̀n (0.038) fún ìṣe-iṣẹ́-sin-ni, àti ìdá ẹyọ (0.022) méjìlélógún fún iṣẹ́ àgbẹ̀ àti ìdá ẹyọ (0.053) mẹ́tàléláàádọ́ta fún iṣẹ́ ìwakùsà ọrọ̀ àlùmọ́nì-abẹ́ ilẹ̀. Ní àfikún, ìdásílẹ̀ irúfẹ́ iṣẹ́ tó pè fún ìwakùsà ọrọ̀ àlùmọ́nì-abẹ́ ilẹ̀ máa mú ìdàgbàsókè iṣẹ́ onígbèésẹ̀ kán-mọ́-kán-mọ́ dání, tí yóò sì ní àfijọ pẹ̀lú irúfẹ́ ipa tí ilé-iṣẹ́ onípèsè ọjà ní.

Àlàyé ìdí abájọ tí ó fi rí bẹ́ẹ̀ ṣe é ṣe pẹ̀lú àjùmọ̀-jọ-rìn-pọ̀ oríṣi ìṣe méjì tí ìdàgbàsókè onígbèésẹ̀ kán-mọ́-kán-mọ́ ti mú wá ní àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ bí i mélòó kan: nínú ìpèsè mẹ́jọ nínú iṣẹ́ tó dojúkọ ìwakùsà ohun ọrọ̀ àlùmọ́nì-abẹ́ ilẹ̀, tí ó mú ìgbésẹ̀ kán-mọ́-kán-mọ́ dání, ìṣe mẹ́fà mìíràn náà dojú kọ ilé-iṣẹ́ ajẹmọ́-ìdókòwò.

Ní àkótán, ìlànà ìdàgbàsókè oníkán-mọ́-kán-mọ́ tí ilé-iṣẹ́ ajẹmọ́-ìdókòwò ní, ṣe okùnfà ìhun aláyìípadà rere fún ìrólágbára tí ó yẹ fún ìdàgbàsókè onípa ọlọ́jọ́ pípẹ́ ní ìgbẹ̀yìn. Àtubọ̀tán tí irúfẹ́ ìfowósowópọ̀ olóòrìn tí ẹgbẹ́ náà ní láàrin ìdàgbàsókè ilé-iṣẹ́ ajẹmókòwò nínú ìṣe àti iṣẹ́ onípèsè èròjà ìlò ni kọ́kọ́rọ́ tó sílẹ̀kùn ìpèsè iṣẹ́ gidi fún ìṣòro Aáfíríkà.

Àwọn ilé-iṣẹ́ ńla dára nípasẹ̀ àgbéjáde ohun àrítọ́kasí tí wọ́n ń ṣe, àti pé wọ́n máa ń sanwó òsìṣẹ́ ju àwọn ilé-iṣẹ́ kéé kèè kéé mìíràn lọ. Ìdá kan nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ti ilé-iṣẹ́ náà fi gbèrùú sí i ní títóbi, ní nnkan láti ṣe pẹ̀lú ìdá ẹyọ hóró (0.09) mẹ́sàn-án ìdá ọgọ́rùn-ún tí agbára ìpèsè ọjà òsìṣẹ́ wọn ní. Ìdápadà ìwọ̀n tí ilé-iṣẹ́ ní lówura ní Aáfíríkà ju ti àwọn agbègbè mìíràn tí ó ṣèṣè ń dìde nílẹ̀ lọ pẹ̀lú ìdá ẹyọ hóró (0.15) mẹ́ẹ̀ẹ́dógún àlékún agbára àgbéjáde òsìṣẹ́ fún ìdá kan nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ìwọ̀n náà. Ipa tí irú ìwọ̀n bẹ́ẹ̀ ní lágbára fún àwọn ilé-iṣẹ́ nlá tí ó n pèsè ohun èlò ní Aáfíríkà, pẹ̀lú ìdá kan nínú ọgọ́rùn-ún ìwọ̀n àníkún ìwọ̀n náà ní àsomọ́ pẹ̀lú ìdá eléyọ horó ogún nínú (0.20) ìdá ọgọ́rùn-ún ìwọ̀n ní ìpèsè àgbéjáde àwọn òsìṣẹ́ – èyí sì fi ẹyọ hóró méjìlá (0.12) ìdá gbéwọ̀n ju ìwọ̀n ìdá fún àwọn ilé-iṣẹ́ tí wọn ń pèsè ìṣe iṣẹ́ -ìsin-ni lọ.

Owó òsìṣẹ́ sísan tún pọ̀ ní iye ju ti àwọn ònsòwò pẹ́ẹ́ pẹ̀ẹ̀ pẹ́ẹ́ lọ, bákan náà ni owó òsìṣẹ́ sísan ju ti ìpèsè ìṣe iṣẹ́-ìsin-ni lọ. Ìdá ọgbọ̀n nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ni ìyàtọ̀ iye tí owó òsìṣẹ́ sísan fi ga ju àwọn ilé-iṣẹ́ kéékèèkéé tó jẹ mọ́ ìpèsè ohun èèlò àti àwọn ilé-iṣẹ́ tí wọn ń pese iṣẹ́ ìsin-ni lọ.

Ìyàtọ̀ nínú àbájádé iṣẹ́ ilé- iṣẹ́ àti owó òsìṣẹ́ bí ó se ipasẹ̀ bí ilé-iṣẹ́ bá tún ṣe tóbi sí àti iye òsìṣẹ́ ibẹ̀ yóò ṣe kàwé tó, àti bí wọn yóò ṣe ní òsìṣẹ́ tí wọ́n mọ iṣẹ́sí ṣe máa pọ̀ tó, bẹ́ẹ̀ náà ni owónàá wọn yóò ṣe máa pọ̀ sí í ju ìgbà tí àwọn ìwọ̀n wọn náà ṣe ní ipa lórí ilé-iṣẹ́, àti bí ó bá se tóbi tó, ni àwọn òsìṣẹ́ kéé kèè kéé, tí owó tí wọn ń pa wọlé ní nǹkan ṣe pẹ̀lú bí òsìṣẹ́ ṣe pọ̀ sí.àbájáde èròjà

Ìpínsísọ̀rí ọjà àwọn òsìṣẹ́ dàbí ẹni pé ó ń ṣe okùnfà àyípadà rere, èyí sì jẹ mọ́ òfin ìgbèrùúsókè ètò ọrọ̀-ajé, tí ó tún mú ìpèsè iṣẹ́ alágbèéká wáyé; bákan náà ni ó ṣe ìfàyè gba ìfagagbága alágbègbè fún àwọn ilé-iṣẹ́ aládàáni àti ìpèsè ìrónilágbára ìṣe èto amútẹ̀síwájú báni tí wọ́n ń ṣe.

ìlò tí ilé-iṣẹ́ ń lá ń ṣe; ní pàtàkì, ní abala ilé-iṣẹ́ tó ń pèsè èròjà ìlò, bákan náà ni ó tún máa ṣe adínà fún àwọn ilé-iṣẹ́ ńlá láti fi ààyè gba pípèsè ojúlówó iṣẹ́ fún ìdàgbàsókè àwọn òṣìṣẹ́ ní Aáfíríkà. Iṣẹ́ rẹpẹtẹ wà láti ṣe, lójú ọ̀nà pé ó yẹ kí a fún àwọn ilé-iṣẹ́ ńlá ní ìwúrí láti dá ilé-iṣẹ́ sílẹ̀ ní Aáfírikà; àti láti ṣe ìrànwọ́ fún àwọn ilé-iṣẹ́ kéékèèkéé láti dàgbà, nípa yíyọ àwọn ìdíwọ́ bí i àìní àwọn ohun amáyérọrùn tó dára, òṣèlú ṣòkèṣodò (tí kò dúró lójú kan fún ìtẹ̀síwájú rere), àti ìwà jẹgúdújẹrá. Ṣíṣe ìdámọ̀ àti àkójọpọ̀ àwọn ìṣùpọ̀ ìwọ̀n tí kò ṣe pàtàkì, lè ṣe okùnfà ìdàgbàsókè fún àwọn ilé-iṣẹ́ náà Ní àpapọ̀, ìwọ̀nba ni àwọn ilé-iṣẹ́ tí wọ́n nífẹ̀ẹ́ sí okòwò fífẹ̀lójú ní Aáfíríkà, pààpàá fún àwọn ilé-iṣẹ́ kéékèèkéé, ìwọ̀nba díẹ̀ ni ààyè tí wọ́n ní láti ṣe àyídà-padà sí ilé-iṣẹ́ alábọ́dé tàbí ilé-iṣẹ́ olókòwò-nlá. Ipa tí àyọrísí ìṣesí bẹ́ẹ̀ ní, ni pé, pípọ̀ yanturu tí àwọn ilé-iṣẹ́ kéékèèkéé pọ̀, máa mú àdínkù bá àwọn. Ìgbésẹ̀ yìí yóò jẹ́ ìgbìyànjú alámọ̀-ọ́n-mọ̀-ṣe, láti ṣàgbékalẹ̀ ètò àfiwéra onírúurú ànfàànì tí dídá ilé-iṣẹ́ ńlá bẹ́ẹ̀ sílẹ̀ ní lÁáfíríkà; lórí àwọn abala ilé-iṣẹ́ tó ń pèsè àwọn ohun èlò fún àwùjọ.

Pípèsè iṣẹ́ gidi àti fífi ààyè gba ìtẹ̀síwájú ọlọ́jọ́ pípẹ́, pè fún fifẹ òkòwò lójú, àti àìdúró-rigidi-lójú kan, nípasẹ̀ ṣíṣe àtúnrọ-túnṣe àwọn ilé-iṣẹ́ tí ó ń ṣe àgbéjáde àwọn òhun èlò àwùjọ, fún ìfẹsẹ̀múlẹ̀ tí ó dára. Èyí gan ni ohun tí ó sáábà máa ń ṣẹlẹ̀ ní Aáfíríkà. Bí ìdàgbàsókè iṣẹ́ onígbèésẹ̀-kán-mọ́-kán-mọ́ bá ti jẹ yọ, àwọn ilé-iṣẹ́ máa ń lè pèsè iṣẹ́ gidi ju iṣe onígbèésẹ̀-kán-mọ́-kán-mọ́ tí ìṣe-iṣẹ́-sin-ni rẹ̀, tàbí ọ̀rọ̀ iṣẹ́ àgbẹ̀, àti dídá ilé iṣẹ́ ìdókòwò aláìní-ìrírí tó yẹ sílẹ̀; àmọ́ tí ó jẹ́ pé ọjọ́ iwájú wọn ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìṣòro. Ṣíṣe àmúgbòòrò onítẹ̀síwájú fún ìdásílẹ̀ ilé-iṣẹ́ olókòwò-nlá ní Aáfíríkà láti ṣe ìtẹ̀síwájú iṣẹ́ tí ó ṣe é mú yangàn àti èyí tí ó ní ààyè fún ìtẹ̀síwájú ni ìwòye pé kí àwọn ilé-iṣẹ́ náà fààyè gba ìdàgbàsókè àti ìgbèrùúsókè tí kò ní ìṣòro tàbí ìdílọ́wọ́ kankan. Lẹ́nu kan, ìwọ̀nyí ni àfihàn àwọn àlàkalẹ̀ òfin àtẹ̀lé fún ilé-iṣẹ́ ìdókòwò àti ìlànà bí àwọn Orílè-èdè ṣe ń ṣe ọ̀rọ̀ ilé-iṣẹ́ ajẹmọ́-ìdókòwò ńlá.

## Onírúurú Ìdíwọ́ Ìdókòwò àti Ìpàdánù Iṣẹ́

Àwọn ìṣòro ìdókòwò náà máa ń ní ipa lórí ilé-iṣẹ́ dídá sílẹ̀ ní ọ̀pọ̀ ìgbà. Ó máa ń wáyé nípasẹ̀ ìgbéléwọ̀n kékeré tí ilé-iṣẹ́ bá ní, nípasẹ̀ mímú ẹ̀mí ilé-iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ tọ́jọ́, àti ṣíṣe àdínkù iye àwọn òṣìṣẹ́. Bí ìdojúkọ ilé-iṣẹ́ bá pàpọ̀jù, irú ilé-iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ lè kógbá-sílé, ní èyí tí ó sì lè fa kí ọ̀pọ̀lọpọ̀ pàdánù iṣẹ́ wọn. Àwọn ilé-iṣẹ́ tí wọ́n bá móríbọ́ nínú ṣòro akónira-báni bẹ́ẹ̀ lè pinnu láti ṣètò àjẹdijú-èrè tàbí kí wọn ṣe àdíkù àwọn àdánù wọn nípasẹ̀ yíyá òṣìṣẹ́ fún àmúlò nígbà tí wọ́n bá nílò òṣìṣẹ́, tí wọn yóó sì tipasẹ̀ bẹ́ẹ̀ lé àwọn kan lọ lẹ́nu iṣẹ́. Ní Aáfíríkà, ipa tí ó tóbi jù lórí iṣẹ́-n-ṣe ni èyí tí ó tipasẹ̀ ìwàláàyè ilé-iṣẹ́ jẹ yọ; ipa tí gbígbani-síṣẹ́ ní lórí àwọn ìṣòro tí ó hànde kò pọ̀ rárá láàrin irúfẹ́ ìṣòro mìíràn tí ó ń dojú kọ àwọn ilé-iṣẹ́ tí ìjì ìṣòro kò gbé lọ.

Ọ̀pọ̀ ilé-iṣẹ́ tí wọ́n bá móríbọ́ nínú ìṣòro àdojúkọ wọn sábàá máa ń borí àdojúkọ wọn, pààpàá, lórí ìṣòro tó bá jẹ mọ́ ìdókòwò, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ilé-iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ máa ń ṣàlàyé nínú àkọsílẹ̀ ìjábọ̀ wọn pé, akùdé ni irú ìṣòro bẹ́ẹ̀ jẹ́ sí ìlàkàka èròngbà ilé-iṣẹ́ wọn. Ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ìdíwọ́ tó jẹ mọ́ ìdókòwò máa ń mú àdínkù bá ète ìdàgbàsókè ìgba-ni-ṣíṣé lọ́dọọdún láàrin ilé-iṣẹ́ tí ó bá jàjàbọ́ nínú ìṣòro tí ó ń bá wọn finra, kódà, wọ́n máa ń ṣe àgékúrú èròngbà bẹ́ẹ̀ fún ọjọ́ orí, láti ìdá ẹyọ hóró kan sí ìdá mẹ́rìn-lé-lọ́gbọ̀n nínú .

Nínú àfojúsùn ìwòye wa, láìṣe àbùmọ́, àpapọ̀ iye iṣẹ́ tí àwọn àjọ agbanisíṣẹ́ láàgbáyé ń pàdánù fẹ́rẹ̀ tó ẹgbẹ̀rún-lọ́nà-ọgọ́rùn-ún-lé-làádọ́rin-lé-méfà ẹgbẹ̀rún (176,000) iṣẹ́ àdáni lọ́dọọdún; nitorí onírúurú ìṣòro ajẹmọ́-ìdókòwò tí a ti ṣe àyẹ̀wò wọn, àpapọ̀ rẹ̀ sì wà láàrin ìwọ̀n mílíọ̀nù kan-ó-lé-méjì sí mílíọ̀nù mẹ́ta-ó-lé-mẹ́ta (1.2–3.3) iṣẹ́. ìdá ọgọ́rùn-ún. Ìtùmọ̀ àyọrísí rẹ̀ ni ìdá ẹyọ hóró kan-lé márùn-ún sí márùn-ún-lé-méjì nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (1.5–5.2) iye àdánù.

Àpapọ̀ iṣẹ́ tí ìwòye wa fi hàn pé wọ́n ń pàdánù n lọ sí ìwọ̀n ẹgbẹ̀rún mẹ́rìn-lé-lọ́gọ́rin (74,000), nítorí àlàkalẹ̀ òfin ìgbẹ́rù-wọlé-jáde àti ti ìdókòwò tó ẹgbẹ̀rún-lọ̀nà igba, àti ẹgbẹ̀rún-lé-

Ṣíṣe ìpèsè iṣẹ́ tó dára àti ìfààyè gba ìdàgbàsókè tí ó ṣe é koná mọ́ fún ìgbà pípẹ́ nílò fífẹ̀lójú lọ́nà tí ohun èlò àmújáde nílé iṣẹ́ náà yóò fi máa jáde dáradára pẹ̀lú ilé-iṣẹ́ tó ń pèsè nǹkan wọ̀nyí.

ìdàgbàsókè tí ó yẹ kí ìgbani-síṣẹ́ ọlọ́dọọdún wọn jẹ́. mẹ́rìn-lé-lọ́gọ́ta ẹgbẹ̀rún (264,000) tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìwé àṣẹ àti àṣẹ lórí kíkó ẹrù òfin wọlé-jáde. Ìwọ̀nba iye tí a fòye rò pọ̀, ni ó já sí iye tí ó ṣe é ṣàlàyé-bó-ṣe-jẹ́, ó sì ṣe é ṣe kí ojúlówó iye iṣẹ́ tí wọ́n ń pàdánù pọ̀ jù bẹ́ẹ̀ lọ ní iye. Àmọ́ ohun tí ó dájú ni pé, àwọn ilé-iṣẹ́ tí ìdásílẹ̀ wọn lo lọ́nà ètó, máa ń ṣe àkọsílẹ̀ ìjábọ̀ lórí bí ìṣòrò ìpádánù wọ̀nyí ṣe jẹ́ akùdé fún wọn tó, nípasẹ̀ àìlè-pèsè iṣẹ́ tuntun àti àìlè-ṣe-ìtójú àwọn iṣẹ tí wọ́n ti pèsè ṣaájú ìdàámú yòówù tí wọ́n bá ní. Gbígba ìwé-àṣẹ àti fífààyè-gba ẹrù òkèèrè ajẹmófin ní kíkó-wọlé-jáde, ọ̀rọ̀ ilé-ẹjọ́, àìfararọ- ọ̀rọ̀ ìṣèlú-ṣèjọba, àti ìwà-jẹgúdú-jẹrá/àìṣòótọ́ jẹ́ onírúurú ìwà tí ó rọ̀ mọ́ orí aládàáni ní Aáfíríkà. Ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà ìṣèjọba; gbogbo àwọn ìṣòro wọ̀nyìí náà ni wọ́n ń pè fún àtúntò-túnrọ rere.

Òsùnwọ̀n mẹ́rìn pàtàkì kan wà tí ó kọ́ra wọn, bẹ́ẹ̀ tí wọ́n máa ń pè fún àṣeyọrí ilé-iṣẹ́, àti ìdàgbàsókè alárìíítọ́kasí fún ilé-iṣẹ́. Òsùnwọ̀n mẹ́rẹ̀ẹ̀rin náà sì ní nnkan láti ṣe pẹ̀lú ẹwù òfin àtẹ̀lé ìdásílẹ̀ ilé-iṣẹ́ náà. Òsùnwọ̀n àkọ́kọ́, tí ó sì jẹ́ pé òun ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ máa ń tọ́ka sí jù lọ, ni mímọ àwọn ètó tó ṣe kokó jù lọ fún ìdásílẹ̀ ilé-iṣẹ́.

Bákan náà, àwọn òṣùnwọ̀n náà jẹ mọ́ pípèsè ànító àti àníṣẹ́kù àwọn ohun amáyérọrùn bí i (ààyè ìlò (ìwúlò) fún ibùdó-iṣẹ́, ìpèsè mọ́tò, ìlànà ìbánisọ̀rọ̀, àti àwọn nnkan mìíràn tó jọra wọn bẹ́ẹ̀), ìpèsè ènìyàn láti lè ṣiṣẹ́ náà, àti àwọn ilé-ẹ̀kọ́ tó ń ṣe iṣẹ́ wọn bí ó ti yẹ.

Ohun kejì ni síse ìdámọ̀ irú ibùdó ọjà tí ìlé-iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ yóò ti ta ọjà tí wọ́n bá n pèsè. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àkọsílẹ̀ àbọ̀ ìwádìí ní Aáfíríkà àti ní àwọn agbègbè mìíràn tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ ń dìde nílẹ̀, ni wọ́n ti ṣe àwárí òye náà pé, ìpèsè ọjà àkójáde di igun kan pàtàkì mú, nínú ààyè láti tètè ní ìdàgbàsókè àti àṣeyinwọ́ lórí okòwò ṣíṣe. Ohun kẹta ni ṣíṣe àṣepọ̀, wíwà papọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹgbẹ́ kan náà láàrin àwọn ilé- iṣẹ́ olókoòwò. Ohun kẹrin ni wíwá ọ̀nà láti fa ojú àwọn olùdókòwò ilẹ̀-òkèèrè mọ́ra.

Ọ̀nà kan gbòógì láti mú àdínkù bá àwọn ìṣòro tó ń dojúkọ ilé-iṣẹ́ ni láti ṣe ìgbàwọlé àti ìdásílẹ̀ agbègbè kan pàtó fún gbogbo àwọn ilé-iṣẹ́ olókoòwò.Ọ̀pọ̀ àwọn ilé-iṣẹ́ ní Aáfíríkà tí ó jẹ́ pé òwò ẹrù kíkó-jáde ni ojú okòwò wọn, ohun tí wọ́n ń ṣe ni pé, wọ́n ṣiṣẹ́ pọ̀ ní agbègbè kan náà, tí kì í jìnnà sí ara wọn; wọ́n sì ń ṣe ìfarakínra tààrà pẹ̀lú àwọn ònsòwò láti òkè-òkun; bẹ́ẹ̀, àwọn olùdókòwò wọ̀nyìí sì jọ ń fagagbága láti rọ́wọ́ mú, láti tẹ̀ síwájú ni. Pẹ̀lú pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà ní ìgbáralé okòwò àwọn ilé-iṣẹ́, ṣíṣẹ́ àmúgbòòrò ètò ọrọ̀-ajé tó fẹjú rẹpẹtẹ jẹ́ ìṣòro ńlá. Ààyè àtilẹ̀ṣe àti ìmọ̀ ilé-iṣẹ́ nípa ìpèsè ohun èlò fún àwọn ènìyàn máa ń mú àyípọ̀ pẹ̀lú àwọn tí ó nílò láti ṣe ìpèsè díẹ̀ nínú irúfẹ́ onírúurú elò ọjà tí ó fẹjú náà.

Ó yẹ kí àwọn aṣòfin ṣe ìdámọ̀ fún irúfẹ́ àwọn nnkan ìpèsè tí àwọn Orílẹ̀-èdè kọ̀ọ̀kan tún lè máa pesè, nípasẹ̀ àìdúró-lójú kan àti àwọn ohun mìíràn tí apá wọn bá ká láti lè ṣe.

Bákan náà, ó yẹ kí àwọn ilé-iṣẹ́ náà wá ojútùú sí ìṣòro tí ó n fa akùdé bá ṣíṣe okòwò wọn; pàápàá, àwọn ilé-iṣẹ́ tí a ti ṣe ìdámọ̀ àwọn kù-dìẹ̀-kudiẹ̀ tí wọ́n ní, tí wọ́n sì jẹ́ èyí tí ó wà ní àrọ́wọ́tó agbára Ìjọba láti bá wọn dojú kọ.

Ohun tí ó yẹ láti máa ṣe ni pé kí àwọn òfin tó rọ̀ mọ́ àgbékalẹ̀ ilé-iṣẹ́ máa wà ní ojúnà láti ṣe àfikún alákòóyawọ́ tí ó ń ṣe àmúlò èrò àwọn tí ọ̀rọ̀ ilé- iṣẹ́ náà kàn. Ní pàtàkì, àwọn ilé-iṣẹ́ aládàáni; kí wọ́n sì ní àfojùsùn nípa ṣíṣe ìdámọ̀ àwọn ìṣòro tí ó jẹ́ kókó jù lọ, láti lè fún wọn ní ànfàání ìfagagbága tó lóòrìn láàrin ara láwùjọ wọn. Àwọn Òrílẹ̀-èdè nílò láti sa ipá tiwọn láti rí i pé wọ́n pèsè ètò ọrọ̀-ajé tí ó ṣe é gbọ́kàn-lé fún kí ó wà, tí kò fi ní í nira, tí yóò sì fún wọn ní ànfàání láti jọ jẹ ọrọ̀ òde àti pé, ṣíṣe àjọ-dòwòpọ̀ tí yóò so èso rere fún ìdàgbàsókè ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́ akíkanjú òṣìṣẹ́. alámùúlégbè wọn, ìdásílẹ̀ ilé-iṣẹ́ sí agbègbè kan náà ye nínú ìlànà àjọṣepọ̀ àwọn Orílẹ̀-èdè àyípàdà rere. Ní ìparí, láti yẹra fún àìríkan-ṣèkan, àti láti rí i pé ìtẹ̀síwájú wà .

Àìní-bodè Aáfíríkà yóò jẹ́ ìpìlẹ̀ rere fún ọjà àgbáyé, láti fààyè gba ìfagbagbága orogún owò, ní èyí tí yóò lè mú ìdókòwò wà láàrin gbugbùn ibi tí ó yẹ. Bákan náà, yóò mú kí iṣẹ́ àgbẹ̀ àti àwọn ilé-iṣẹ́ tí ó ń pèsè ohun èlò búrẹ́kẹ́ sí i, kọjá rere lójú àwọn olùdókòwò, nígbà tí àyọrísí ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀ yóò fààyè gba ìdókòwò ọjà tí ó fẹjú, tí wọ́n sì ń ṣe ìpèsè ààyè tuntun fún àwọn onílé-iṣẹ́ ìdókòwò kéékèèkéé àti nínlá. Láìsí àní-àní, ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀ yóò fààyè gba dídẹ́kun ọjà àdátà-gbèdéke àwọn ibodè kan lágbàáyé. Yóò sì tún jẹ́ kí ìpèsè irúfẹ́ ọrọ̀-ajé wọn ní òdiwọn ẹlẹ́yọ ẹnìkan, tí yóò sì fi ìrànwọ́ bá àṣẹ́kù-ṣẹ́ẹ̀lẹ̀.

## ÀJỌṢEPỌ̀ FÚN ÌTẸ̀SÍWÁJÚ ỌRỌ̀-AJÉ AÁFÍRÍKÀ

Àjọṣepọ̀ tí ó wà láàrin gbígbé ẹrù kọjá ẹnu ibodè òkè-òkun; àwọn agbègbè omi àti àwọn Orílẹ̀-èdè mìíràn tí omi ti dè mọ́ ibodè sí òdì-kejì bẹ́ẹ̀. Kọjá ojú eréfèé, àjọṣepọ̀ àdàpọ alágbègbè lè ṣe ìgbèrùúsókè agbára ààbò, nítorí pé, ìfẹ̀lójú ìdókòwò ọjà àgbáyé máa ń ṣe okùnfà àdínkù bá onírúurú àwọn aáwọ̀ láàrin àwọn Orílẹ̀-èdè tí wọ́n bá ń ní àjọṣepọ̀.

### Àdínkù Àwọn Owó-Orí Sísan Àti Ìṣòro Iṣẹ́ Alàìlówó-Orí Sísan

Ìrètí àkọ́kọ́ nínú jíjẹ ànfààní àdéhùn láàrin àwọn olùdókòwò ni àlékún okòwò bẹ́ẹ̀ láàrin àwọn akẹgbẹ́ wọn, tí ó ní ẹka ọ̀nà mẹ́ta — ohun àkọ́kọ́ ni mímú àdínkù bá owó sísan lórí àwọn ọjà tí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ bá ń ṣe òwò rẹ̀. Ohun kejì ni, mímú àdínkù bá owó àwọn ọjà tí kò ní owó-òfin sísan lórí, ní èyí tí ó tipasẹ̀ òfin àlàkalẹ̀ hù jáde àti àwọn owóyàá tàbí owó sísan tí kò ti ara gbèdéke òfin àtẹ̀lé ìdásílẹ̀ hù jáde. Ohun kẹta, tí ó sì dà bí òfin tí ó yi tikẹ́ láti ṣe ni, láti ipasẹ̀ àwọn ohun méjì tí ó máa ń ṣe òkùnfà òwò ṣíṣe: Èròjà àrígbámú, tí ó sún mọ́ àwọn ìpèsè amáyérọrùn bí i ìdíkọ̀ ojú-omi, ojú-ọ̀nà ọlọ́dà geere fún mọ́tò, ìpèsè ìlànà-ìbánisọ̀rọ̀, ìpèsè àwọn èròjà ìrọ̀rùn mìíràn tí wọ́n ṣe é fòyemọ̀ láyìíká, tí yóò sì hàn sí àwùjọ pé, ohun gbogbo ní àkóyawọ́, àmójútó ìṣèjọba òfin tí ó rọ̀ mọ́ ẹrù kíkó wọlé àti jíjáde ní ibodè, ìpèsè ibùdó ìdókòwò fún àwùjọ, àti àwọn nnkan amáyérọrùn mìíràn tí ó lè fẹsẹ̀ ìdókòwò múlẹ̀ lọ́nà ìrọ̀rùn. Àwọn òdiwọ̀n méjì àkọ́kọ́ ni wọ́n dàbí i àbájáde òsùnwọ̀n tí a ṣàjọ jáde lábẹ́ àjọṣepọ̀ tí kò hànde dáradára; nígbà tí ẹ̀kẹta jẹ́ ìwòye òfin tí ó rọ̀ mọ́ ìdàpọ̀ tí ó lóòrìn gidi.

### Ìsọdipúpọ̀ Ìpèsè Iṣẹ́ Alágbèéká

Yíya-lọ kúrò láti àwùjọ kan sí òmíràn ti ń ṣẹlẹ̀ ní Aáfíríkà. Bí kì í tilẹ̀ ṣe pé gbẹdẹmukẹ ni àwọn ènìyàn ń rin ìrìn yíya-lọ náà, ìgbésẹ̀ gbígbéra láti ibì kan lọ sí èkejì àwọn ènìyàn ti jẹ́ èyí tí ìfọwọ́sí wà fún lábẹ́ òfin, tí ó sì ti di àmúlò. Bí òfin yíya-lọ bá ní àfowọ́sí lẹ́kún-ún-rẹ́rẹ́, ìwọlé-wọ̀de ọ̀pọ̀ ọmọ Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà láàrin ara wọn yóò fi pọ̀ sí i ni. Èyí ni ó fi ṣe pàtàkì láti dojú kọ àwọn ìṣòro tí ó lè fa àìṣàmúlò àwọn òfin náà. Ìwé ìrìn-àjò ìdánimọ̀ tí Aáfíríkà ṣe ìfilólẹ̀ rẹ̀ ní Oṣù Keje ọdún 2016 ní ibi ìpàdé Àpérò kan tí wọ́n pè ní “African Union Summit” tí ó wayé ní Kigali, fún àwọn ènìyàn ní ànfààní ìrìn òmìnira láàrin ara wọn, pàápàá irìn-àjò láti ṣiṣẹ́ àlágbèéká alàìfòfin-dan-in-dan-in dè. Bákan náà ni ó jẹ́ pé ète àkọ́kọ́ nínú èròngbà Àjọ́ Aáfíríkà lágbàáyé ni láti ní Ibùdó Ìdókòwò Olómìnira, láti lè pèsè ààyè kan pàtó fún ìpèsè ọjà àti agbo ìdókòwò tí ó fààyè gba ọlọ́danni kọ̀ọ̀kan; àti láti jẹ́ kí àtètè-fi-lọ́lẹ̀ Àjọ Àpapọ̀ Aáfíríkà fún Àjọṣepọ̀ LÁgbàáyé- “*Continental and Customs Union and the African customs union.”* hù jade kíákíá -

Fún àwọn nnkan ìwùrí wọ̀nyìí láti wá sí ìmúṣẹ dé ibi àṣeyọrí. Ó dára láti kọ́kọ́ tẹ̀síwájú fún ìpèsè àwọn òfin àtẹ̀lé nítorí ìṣàmúlò àwọn ètò ìṣúná kọ̀ọ̀kan fún agbègbè wọn - (*Regional Economic community)* (REC) kí ó tó di pé a bẹ̀rẹ̀ sí ní i fi òṣùnwọ̀n náà ṣe ti Àjọ Àgbáyé. Àjọṣepọ̀ Aládàpọ̀ ye kí ó wáyé, kì í ṣe lórí ọ̀rọ̀ inú ọjà ìdókòwò nìkàn, ṣùgbọ́n pẹ̀lú àwọn ìdí abájọ mìíràn tí ó jẹ mọ́ àyọrísí ìpèsè àwọn èròjà ìlò; àwọn àlàyé wa yẹ kí ó tún dagun sórí fífi ààyè gba àwọn ènìyàn láti rin ìrìn alàìfi-òfin-ìdè-mú láàrin àwùjọ wọn.

### Ṣíṣè Ètò Ọjà Oníṣùú-ná Àdájọná

Pẹ̀lú ìtẹ̀síwájú tí ó ti ń wà, ìwòye wa ni pé, ní Aáfíríkà, ọjà oníṣùú-ná àdájọná kò tí ì lágbára bí ó ṣe yẹ. Ìṣesí òdiwọ̀n òfin àwọn ilé-iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan ṣàfihàn àṣírí pé, ọ̀pọ̀lọpọ̀ nnkan ni ó yẹ kí ó ti jẹ́ ṣíṣe láìṣe, láti ipasẹ̀ ìlànà ìṣèjọba. Ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàrin àsùnwọ̀n àfipamọ́ nínú ilé àti èlé owósan okòwò fesẹ̀rinlẹ̀ gidi, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, ó ti yẹ kí ó máa dínkù, nítorí àìsí ìdíwọ́ lórí ọ̀rọ̀ gbígbé owó láti ibì kan si èkejì. Àyípọ̀-pín-kárí èlé orí owó lórí àwọn ilé-ìfowópamọ́ kéékèèkéé túnbọ̀ ń fejú sí i, ṣùgbọ́n èyí ti wà ní ààyè tí ó yẹ láti bí i ọdún díẹ̀ séyìn. Bákan náà, Àjọ ọjà ohun-ọrọ̀ Aáfíríkà jẹ́ èyí tí ó ní ìtara sí ọ̀rọ̀ ètó òdiwọ̀n àgbáyé ju ìṣe ti ètó òdiwọ̀n South Aáfíríkà lọ. Láìṣègbè rárá, àtúntò-túnrọ fún ìlànà àgbékalẹ̀ Àjọ jẹ́ ohun tí ó gbọdọ̀ wáyé; pàápàá, láti jẹ́ kí àjọṣepọ̀ tí ó ṣe wẹ́kú lórí ètò ìṣúná ìjọba, tí a gbé sórí òté ìbágbègbè-ṣe àṣepọ̀ gidi wà, àti láti yọ ọwọ́ àwọn ìṣòro aje-mọ́-ọ̀rọ̀ òfin tí ó ń ṣokùnfà ìdíwọ́ fún lílọ-bíbọ̀ ọ̀rọ̀ okòwò ní ìrọ̀rùn kúrò. Ẹ̀wẹ̀, ó dára láti ṣe ìlépa mímú àwọn nǹkan ìmọ̀-ẹ̀rọ ìgbàlódé gbèrùú sí i, lọ́nà tí ìlànà láti san owó

Wíwà láìníbodè Aáfíríkà jẹ́ ìpìlẹ̀ rere kan fún òkòwò aláì-dá-jẹ-gàba, èyí tí ó fààyè gba ìfagagbága okòwò ṣíṣe ní àgbáyé; bẹ́ẹ̀ ni yóò le ṣe ìpèsè fún ibùdó ìdókòwò káríayé. Ìjọba nílò agbára àjùmọ̀jọṣe-pọ̀ tí yóò fààyè gba ìgbésẹ̀ ìṣèjọba agbègbè fúnra wọn, àjọ agbègbè náà sì gbọdọ̀ jẹ́ èyí tí ó dá ní àṣẹ tòótọ́ lórí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ wọn ní ìjọba ìpínlẹ̀ láti lè ṣe àmúlò ohun èlò àwùjọ fún àwọn ènìyàn agbègbè náà.

láàrin òǹràjà àti òǹtàjà lágbàáyé yóò fi rọrùn; nítorí pé, ìrọrùn yìí gan an ni yóò fàáyè gba ìbádòwòpọ̀ aláìlábàwọ́n àti fífi owó ránṣẹ́ láti agbègbè ibodè kan sí èkejì láìní ìnira.

Gẹ́gẹ́ bí àmúgbòòrò fún Àjọ Àjùmọ̀-jọdàpọ̀-ṣe lágbègbè, àwùjọ rí àwọn ẹgbẹ́ tí ó jẹ mọ́ olókoòwò ìdókòwò bẹ́ẹ̀ ní Aáfíríkà gẹ́gẹ́ bí ìdásílẹ̀ àjọ láti sọ ara wọn di ọlọ́rọ̀; àti ọ̀nà láti ṣe ìjọba tí ó dára ju èyí tí kò sí ni ẹgbẹ́ wọn lọ; kódà, wọ́n ṣe àgbékalẹ̀ àjọ náà lọ́nà tí ó fi fẹ́rẹ̀ fara pé Àjọ Olókoòwò Àjùmọ̀-jọdàpọ̀-ṣe Ìdókówò Ilẹ̀ ọba àwọn aláwò-funfun - (*European monetary integration*). Ṣùgbọ́n ẹgbẹ́ Olókoòwò Alájùmọ̀-jọdàpọ̀-ṣe ní Aáfíríkà kò kógo já tó, lójú ìgbéléwọ̀n wọn, wọ́n kùnà láti mú àdínkù bá òṣì àti àìní àwọn ènìyàn, bákan náà ni wọn kò ṣe ìtẹ̀síwájú ọrọ̀-ajé/ètò ìṣúná àyíká wọn.

Ìgbésẹ̀ àjùmọ̀jọṣẹ̀-jọba pè fún ìṣèjọba agbègbe láti ọwọ́ àwọn tí ó ní àṣẹ lórí àwọn akẹgbẹ́ ìpínlẹ̀ wọn yóòkù láti lè ṣe àmújíṣẹ́ erù ìlò àwùjọ

Láìmọye ìgbà, kódà àwọn ìbéèrè ọ̀rọ̀ ìdókòwò kéékèèkéé aláìmú-ófin-dání tí kò sì gara láti ṣe mìíràn wà àwọn ẹgbẹ́ náà kò rí yanjú. Bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn aṣaájú olóṣèlú ní Aáfíríkà ń gbèrú láàyè ara tiwọn láìkókó gbé ìgbésẹ̀ akin láti mójútó ìdásílẹ̀ àwọn àjọ àti ètò ìṣúná tí ó lè sọ ọ̀rọ̀ ẹgbẹ́ olokoòwò di níńlá, nípasẹ̀ àjùmọ̀-jọ-ṣe-pọ̀ wọn ní Aáfíríkà. Níbi tí kò bá ti sí ètò ìṣúná-owó àti àmójútó ọrọ̀-ajé gidi, àǹfààní láti ṣe àmójútó iye tí owó nínà ẹlẹ́yọ kan jẹ́, máa n wọn jù.

Nígbà tí ète ìfohùnsọ̀kan tí ó ṣẹ̀dáà àjùmọ̀-jọ-ṣe-pọ̀ ẹgbẹ́ Aáfíríkà ní àfojúsùn ìlò owó nínà kan péré fún Aáfíríkà, àti ààyè ibùdó kan náà lágbègbè, èrò Ajọ (RECs) ní láti ṣẹ̀dá owó nínà kan fún agbègbè wọn; àmọ́ èròngbà lásán ni ó jọ lọ́pọ̀ ìgbà, nítorí pé kò sí òfin àtẹ̀lé kan dan-in dan-in ní àkọsílẹ̀ fún Orílẹ̀-èdè lórí ọ̀rọ̀ owó nínà náà, tí ó fi lè mú èròngbà náa wá sí ìmúṣe. Àwọn Orílẹ̀-èdè nílò láti fi sí orí èrò fún àmúṣe, kí ibùdó ajọ kan wà, ní èyí tí yóò mú kí èròngbà lórí ẹgbẹ́/àjọ olókoòwò ìdókòwò wà, kí àmójútó àti ìṣàkóso jẹ́ ohun pàtàkì fún àwọn ilé-ìfowópamọ́, bẹ́ẹ̀ ni yóò jẹ́ ète àmọ́-ọ́n-mọ̀-ṣe láti ran àwọn Orílẹ̀-èdè tí ó bá wà nínú ìṣòro ọrọ̀-ajé lọ́wọ́, àti pé kí àgbájọ ètò ìṣèlú máa jẹ́ alákòóso àti alámòójútó fún àtẹ̀lé ètò òfin ajẹmọ́-ọrọ̀-ìṣúna owónàá àti gbogbo àìnító tí ó bá fara hàn.

## Ṣíṣe àfikún Agbára Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ fún Ìpèsè Àwọn Èròjà Ìlò Àwùjọ

Àjùmọ̀-jọ-ṣe-pọ̀ alágbègbè ti máa ń jẹ́ ọjà ìrọ̀rùn fún àwọn ènìyàn láti wò. Bákan náà ni àjùmọ̀-jọfọwọ́-sowópọ̀ alágbègbè ti di igun pàtàkì mú ní àwùjọ tipẹ́, bí ó bá tilẹ̀ jẹ́ nítorí pé ìlò ìpèsè àwọn ohun amáyérọrùn bí i ojú-ọ̀nà rélùwéé, ọ̀nà má-rosẹ̀, àti àwọn ọ̀nà mìíràn tí a fi ń bára-sọ̀rọ̀, ní báyìí, ti n di èròjà àmúlò tí ó ń wu àwọn ènìyàn àwùjo fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdí. Kọjá èrò àwọn Àjọ (REC) méjèèjọ àti àwọn Àjọ agbègbè méje mìíràn tí wọ́n ní àfojúsùn láti ṣe ìfẹsẹ̀múlẹ̀ ètò ìdókòwò aláfolémọ-kọjá agbègbè, ohun tí ó jẹ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn Ajọ agbègbè lógún tí wọ́n ń mójútó ni ìpèsè èròjà ìlò àwùjọ bí i: kí wọ́n yanjú ìpèsè iná-ẹ̀lẹ́tíríkì márùn-ún (5), ìpèsè àmójútó / ìṣàkóso àwọn odò omi ńlá àti omi adágún mẹ́ẹ̀ẹ̀dógún (15), ìpèsè àlàáfíà àti àwọn ẹ̀só aláàbò mẹ́ta (3), àti ìpèsè ẹyọ hóró kan (1) fún àyíká.

Àjùmọ̀-jọfọwọ́-sowópọ̀ agbára ìṣe tí àpapọ̀ ìjọbá bá ní ní agbègbè kan yẹ kí ó tó láti ṣe ìpèsè ànító àti àníṣẹ́kù àwọn ohun amáyérọrùn tí ó dára yíká gbogbo agbègbè nínú àṣẹ́kù-ṣẹ́ẹ̀lẹ̀ wọn, ju èyí tí ẹyọ ọlọ́danni ìjọba kọ̀ọ̀kan máa lè dá pèsè lọ. Ìdí nìyí tí ìṣèjọba agbègbè láti ọwọ́ àwọn Àjọ agbègbè tí wọ́n ní àṣẹ tòótọ́ lórí àwọn ọmọ ẹgbẹ́, ní ìjọba ìpínlẹ̀ tí wọ́n ti jẹ́ ọ̀kan náà fi lè ṣe àgbékalẹ̀ ìpèsè èròjà ìlò àwùjọ wọn, àti ìjábọ̀ rere fún àwọn agbègbè wọn. Àwọn Ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan gbọdọ̀ ṣetán láti ṣe àfisílẹ̀ àṣẹ tàbí agbára tí ó lówura tó, fún àwọn Àjọ kan; èyí tí í ṣe irú ìgbésẹ̀ tí ó ti wáyé sẹ́yìn ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àkókò sẹ́yìn, ní àgbáríjọ àwùjọ ẹgbẹ́ àwọn Òyìnbó – European Union. Ìdí abájọ nìyí tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ agbègbè ṣe ní ìṣèlú onírìísí àjùmọ̀-jọ-ṣe-òfin-ṣèjọba lágbègbè. Ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan yẹ kí wọ́n ní agbára abàṣẹ-wàá, àti pé, Àjọ agbègbè kọ̀ọ̀kan ni ibùjókòó ìṣèjọba tí ó ń ṣàmójútó, ṣe-àkójọ-pọ̀ àwọn òfin àtẹ̀lé fún ìdásílẹ̀ àti ṣíṣe òdiwọ̀n àmúlò òfin tí ó tọ́, tí wọ́n sì ń pèsè ìrànlọ́wọ́ ojúṣe tí ó bá yẹ – ṣùgbọ́n láìní àṣẹ kankan.

### *Àrígbámú Ohun Amáyérọrùn*

Ìpèsè Ojú-ọ̀nà, Ìdíkọ̀-ẹrù-ojú-omi, ọ̀nà Ìrìn-ojú Òfuurufú, Reluwéé, Ojú-tò-ọ̀pá epo, àti àwọn ọ̀nà ìgbà-bára-ẹni-sọ̀rọ̀-pọ̀ ti jẹ́ ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ agbára

pàtàkì fún àjùmọ̀-dàpọ̀-ṣe-pọ̀ fún Aáfíríkà, ọjọ́ ti pẹ́.

Bákan náà, láìpẹ́ yìí, Orílẹ̀–èdè China àti àwọn Àjọ *African Union Commission* jọ buwọ́ lu ìwé àdéhùn ọlọ́jọ́-pípẹ́ kan, lábẹ́ àká èròngbà àti nínú ìwòye àfojúsùn wọn fún ìtẹ̀síwájú, pé, kí ó tó di ọdún 2063, ní ìṣewékú pẹ̀lú èròngbà *African Union's Agenda 2063* láti ṣe ìpèsè àwọn nnkan àrígbámú amáyérọrùn tí yóò ṣe àsopò fún àwọn olú ìlú Aáfíríkà nípasè pípèsè ojú-ọ̀nà–ìrìn mótò, reluwéé, àti ọkọ̀-ojú òfùùrùfú.

Nípa mímú àdínkù bá owó ọjà, pípèsè ojú-ọ̀nà–ìrìn mótò tuntun, ọ̀pọ̀lọpọ̀ reluwéé, àti ọkọ̀-ojú òfùùrùfú, ìwọ̀nyìí yóò jẹ́ kí okùnfà ìbáṣepọ̀ rere fẹsẹ̀múlẹ̀ láàrin àwọn ìlú nlá-nlá, bákan náà ni yóò fààyè gba ìdàgbàsókè nlá bá ìlú, yóò sì mú kí ààyè àtilẹ̀ṣe wà fún ìtẹ̀síwájú alájùmọ̀-jọ-ṣe-pọ̀ ìrọrùn, láti pèsè ìdókòwò rere, àti láti mú kí àmúgbòòrò bá ìpèsè ohun èló amáyérọrùn àrígbámú tí yóò ṣe àfikún òwò tí ó lè mú èrè gọbọi bá ètò ìdókòwò. Lọ́nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ètò okòwò tí kò bá sí àmójútó rẹ̀, a máa ṣe ìjákulẹ̀ àti àdínkù bá èrè ìnájà, ní èyí tí ó sì lè mú kí ọjà gbé owó lórí gegere, kí nǹkan má sì ṣe déédé fún àwọn òǹṣòwò. Ojúlówó ìpèsè àwọn ohun amáyérọrùn-fún-ni-lò tí ó bá wà ní àwùjọ kan àti bí àwọn nǹkan ìpèsè náa bá ṣe pò tó ni ó máa ń jẹ́ okùnfà iye àwọn owó ọjà àwujọ náà.

### *Èròjà Amáyérọrùn Aláràìtọ́kasí*

Láti lè ṣe àṣeyọrí lórí ọ̀rọ̀ ẹrù kíkó wọlé-jáde, àwọn àmúlò ọgbọ́ndàá kan wà tí ó gbọdọ̀ àmúlò àǹfààní fún ọ̀rọ̀ ìgbòkè-gbọdọ̀ ọkọ̀ tí yóò jẹ́ atọ́nà fún àjùmọ̀-jọṣe-pọ̀ agbègbè.

Fún aṣegboríyìn iṣẹ́ tí ó jẹ mọ́ mọ́tò gbígbà-wọ́lé, ẹrù kíkó, ẹrù-fífi-ránṣẹ́ àti àmójútó ìdíkọ̀ àwọn ibùdókò ìrìn-àjò, gbogbo àwọn ohun tí ó bá yẹ láti mú ṣe, ni ó ṣe pàtàkì. Àwọn ọjà aláàtò-ọgbọ́ndàá ìṣe máa ń ṣe àṣeyege nígbà tí ààtò gbígbà-wọlé, ẹrù kíkó, ẹrù-fífi-ránṣẹ́ àti àmójútó ìdíkọ̀ àwọn ibùdókọ̀ ìrìn-àjò bá ti wà ní àwọn agbègbè tí ààyè ti wà fún ìfagagbága òwò aláìjẹgàba ẹyọ ẹnìkan, àti pé, àwọn ẹrù tí àwọn ènìyàn bá fẹ́ fi sọwọ́ sí ibùdó mìíràn tàbí fún gbígbà-jáde ní akolo àwọn aláṣẹ ayẹ̀wé-ọjà-òkèèrè-wò máa ń yá kíákíá. Okòwò ọjà tí kò bá sí ààtò-ọgbọ́ndàá ìṣe fún máa ń ní ìṣòro púpò láti dojukọ-yanjú, ju òwò tí àwọn owó ìwé aṣe-sísan àti ọjà tí kò ní owósan lé lórí lọ. Àìní ààtò-ìṣedéédé fún okòwò máa ń fa akùdé bá ìtẹ̀síwájú àjùmọ̀-jọṣe-pọ̀ agbègbè tí ó yẹ kí ó ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ànfààní, pàápàá níbi tí ó bá ti yẹ kí àwọn ẹrù náà ti gba ẹnu ibodè wọlé ní ọ̀pọ̀ ìgbà, tí ó bá wà lábẹ́ àkójọ.

Àwọn ìṣòro ìdókòwò tí ó jẹ mọ́ ẹnu ibodè ti fìdí janlẹ̀ láti bí i nnkan ogún ọdún séyìn. Ní àgbálọgbábọ̀ èrò, ìlànà ìwòye yìí dábàá mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Lákọ̀ọ́kọ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ẹnu ibodè sì máa ń “kún bàbì” (fún ènìyàn), a wòye pé wọ́n ti n yàtọ̀ nípa “ìdẹyọ díẹ̀ díẹ̀” báyìí, tí ó sì ti ń mú èrò àyípadà dé bá àjùmọ̀-jọṣe-pọ̀ agbègbè, pàápàá pẹ̀lú àkosílẹ̀ ìjábọ̀ èròngbà wọn ní Aáfíríkà pé, ìfọkànṣe àwọn iwé àwọn ibùdókọ̀ bẹ́ẹ̀ ti ń gbèrú sí i. Lọ́nà kejì, jíjẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ tí ó ní ìfohùn-ṣọ̀kan okòwò alágbègbè kò dà bí i pé o ní ipá lórí àkópọ̀-jọṣe-àṣepọ̀ rárá. Lọ́nà kẹta, ìgbésẹ̀ ríran òkòwò lọ́wọ́ — n ṣe àfihàn ara agbára tí ó lè mú kí àjùmọ̀-jọ-ṣe-pọ̀ agbègbè àti ìpalẹ̀mọ́ tòótọ́ fún àjùmọ̀-jọ-ṣe-pọ̀ ní ìtumọ, tí ó sì lè ṣe ẹ̀rù ba ẹrù àìdúró déédé ìtẹ̀síwájú jákè-jádò àgbáyé nìyẹn, nípa jijẹ́ aṣaájú sí ìdàgbàsókè àwọn àwùjọ tí kò tí ì fi bẹ́ẹ̀ gbajúgbajà rárá.

### *Àdínkù Owó Ọjà láti ṣe Àfikún Owó Ìkópa nínú Ìpèsè Ọjà Ìdókòwò*

Ète pàtàkì kan tí àmúwáyé Àdéhùn Ọjà Ọ̀fẹ́ (Free Trade Agreement) ní, ni láti ṣe àfikún ìkópa àwọn olóko-òwò láti ilẹ̀ ìbòmíràn, àti láti mú àdínkù bá àwọn ìpèsè ọjà, àti láti mú owó orí ọjà wálẹ̀ nípasẹ̀ àjùmọ̀-jọṣe-pọ̀ òwò lágbègbè. Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà ti kópa díẹ̀ nínú ìpèsè ọjà àgbáyé, àti nínú ìgbìyànjú àwọn ìṣe wọn mìíràn tí ó fààyè gba ìṣe akọ́ra-bí-òwú alántakùn; àmọ́, nínú àwọn ìdáwọ́lé tí ó jọ ti ìpèsè àwọn ọjà tí kò tí i parí, tàbí èlò tí kò nílò àtúnrọ ni wọn kò dá sí irú akitiyan bẹ́ẹ̀. Ṣùgbọ́n ìrírí òwò àwọn nǹkan bí i aṣọ ṣíṣe (híhun, títẹ̀, aró rírẹ / dídì) àti rírán, ìsọ̀ gbogbolòwò-àtẹ, (supá-makèètì), àti òwò gbogbo-nìṣe- oníwóróbo ṣe àfihàn Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà gẹ́gẹ́ bí àwùjọ tí ó ń gbèrú síwájú nínú òwò ṣíṣe, pẹ̀lú ipa taakun-taakun wọn nínú ajùmọ̀-jọṣe-pọ̀ òwò alágbègbè kan náà. Kọ́kọ́rọ́ tí ó ṣàfihàn òye yìí ni àdínkù owó ọjà bí ẹrù bá ti ń gba ojútò bodè orílẹ̀-èdè gbogbo kọjá ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà. Láti ṣe àmúgbòòrò ọ̀wọ́ ìpèsè àwọn ẹrù à-gbé-wọlé-gbé-jáde àti láti ṣe àtúnṣe-túnrọ sí ìlànà àmójútó iṣẹ́ àwọn ayẹ̀wé-òfin-ẹrù ìbodè-wò, àti láti ṣe ìtẹ́wọ́gbà ìlànà òfin ìrọrùn tí ó tún farahàn sí àwùjọ, ó ṣe pàtàkì. Ní àtètè-múse èrò - *WTO's Trade Facilitation Agreement* - ìgbèsẹ̀ náa yóò ṣe àdínkù àwọn ọ̀wọ́ ọjà, ní èyí tí àwọn

ènìyàn /ọmọ ẹgbẹ́ Aáfíríkà – World Trade Organization(WTO)- yóò lè ṣe. Àwọn àjọ WTO ṣe ìwòye pé ṣíṣe àdínkù lórí ọ̀rọ̀ àkókò ní bode àwọn ayẹ̀wé-ẹrù-òfin-wò tún lè ṣe àgékúrú owó ọjà bí i ìdá mẹ́ẹ̀ẹ́dógún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún fún àwọn Orílẹ̀-èdè tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ ń dàgbàsókè.

Nínú àwọn ìwòye mìíràn gẹ́gẹ́ bí òté àwomó fún Orílẹ̀-èdè tí a fi ṣe àkọsílẹ̀ èrò yìí, ẹrí wà pé onírúurú èrè ni ó lè ti ibi ṣíṣe ohun gbogbo ní ìlànà tí ó hànde sí àwọn ènìyàn, àti ṣíṣe àdínku àwọn òfin àbàadì láti ọ̀dọ̀ àwọn ayẹ̀wé-ẹrù-òfin-wò.

Níbi ti àmúgbòòrò àdéhùn okòwò ojú-ṣàájú ṣíṣe àti àwọn ìgbèsè òwò nínú àwọn ìṣe taakun-taakun bá ti wáyé, òfin ìpìlẹ̀ gbọdọ̀ jẹ́ àmúlò.

**Ó ṣe pàtàkì láti ṣe àmúgbòòròsí ìpèsè ọjà fún ìtẹ́síwájú, ìṣẹ́ àmójútó àwọn Ayẹ̀wé-ẹrùòfin-ibodè-wò, àti láti ṣe ọ̀nà ìtẹ́wọ́gbà tí ó rọrùn, tí ó sìfojú hàn sí gbogbo-gbòò bí i tipìlẹ̀ ti wọ́n ti fi ń ṣiṣẹ̀ lọ.**

Ọ̀kan lára àwọn ìṣòro “òfin oníṣòkè-ṣodò” / “ṣíṣe ojú púpọ̀” nínú àmúlò òfin ni pé, irú àjùmò-jọṣe-pọ̀ agbègbè bẹ́ẹ̀ yóò ṣe ìdíwọ́ òfin ìpìlẹ̀ láti ṣiṣé gẹ́gẹ́ bí ète àgbékalẹ̀ rẹ̀ tí ó fi jẹ́ pé, àyípadà àwọn òdiwọ̀n agbègbè bẹ́ẹ̀ le nípa lágbàáyé. Kò ṣàbà sí ibi tí ìṣòro yìí ti peleke jù lọ, bí kò ṣe ní àyíká Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà nínú Àjọ *REC*. Nígbà tí òfin ìpìlẹ̀ ṣe pàtàkì láti múlò fun ẹrù kíkó-jáde lọ sí òkèèrè, láti ṣe adínà fún fífi-ẹrù-ránṣẹ́, bí òfin onígbèdéke bá ti pọ̀ jù, ńṣe ni wọ́n máa jáwọ́ nínú òwò ọjà tí ó ń fún wọn ní àdáyọ-fún-ní-àǹfààní tí àwọn ẹrù yòókù kò ní lọ, nítorí pé, irúfẹ́ àwọn òfin ajẹ-mọ́-ẹrù kọ̀ọ̀kan wà tí ó jẹ́ òfin ìpìlẹ̀, tí wọ́n maa ń lò láti ṣe àtẹ̀lé-mójútó fún ẹni tí ó pèsè ẹrù bẹ́ẹ̀ fún àábó pípé.

## *Ṣíṣe Àmúlò Àǹfààní Ìdókòwò Àgbáyé Ìdókòwò ÀjọÌpèsè Ìrọ̀rùn/ Ìrànlọ́wọ́*

Àdínkù àdéhùn lórí àwọn ìṣòro tí ó ń dojú kọ àwọn òǹràjà nínú okòwò wọn lè ṣe okùnfà àfikún èrè ìsúná *GDP* lágbàáyé - láti nǹkan bí i ìgbà mẹ́fà, lọ́nà ìlọ́po mẹ́sàn-án (*up to 6 times*) ju kí wọ́n yọ owó-sísan orí ẹrù ọjà wọn lọ. Bí gbogbo Orílẹ̀-èdè bá lè ṣe àkópọ̀ ìdarí ìṣàkóso ẹnu ibodè ẹrù, pẹ̀lú ìpèsè ọ̀rọ̀ ojúnà ọkọ̀ àti ìlànà ìbánisọ̀rọ̀, kí wọn sì ṣe òdìwọ̀n, kódà, ìlàjì ìṣe-káríayé, èrè àgbáyé wọn (GDP) yóò gbérasọ láti ìwọ̀n tírílíọ̀nù dọ̀là méjì- ó-lé-tírílíọ̀nù mẹ́fà ($2.6 trillion) - tí ó já sí, ìdá mẹ́rin-ó-lé-méje nínú ìdá ọgọ́rùn-ún- (*4.7 percent*), nígbà tí àpapọ̀ owó-náà àkójáde yóò ti lé sí i ní ìwọ̀n tírílíọ̀nù dọ̀là kan-ó-lé mẹ́fà tírílíọ̀nù dọ̀là ($1.6 trillion) – tí òun náà jẹ́ ìdá mẹ́rìnlá-ó-lé- márùn-ún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (*14.5 percent*).

Láìsí ìrújú kankan, àǹfààní asopọ̀ àgbáyé ti jẹ́ òdìwọ̀n / àwòta ìṣe fún ìdókòwò. Bákan náà, bí a ṣe wòye rẹ̀, irú àwọn Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà bí i Rwanda, àti (Ethiopia àti Morocco) ti n lo àǹfààní àyípadà rere yìí ní tiwọn. Dípò tí wọn yóò fi máa fi àkókò ṣòfò lórí ìfọ̀rọ̀jẹ̀wọ̀ nìkan, tí kò mú ìlọsíwájú bá ìlànà òfin èlé owó-orí ẹrù, àwọn Orílẹ̀-èdè náà ti ń ṣe àtúntò-túnrọ sí ọ̀nà ọgbọ́ndáà tí ó ṣe àfojúsùn lórí ìrànlọ́wọ́ fún ìdókòwò.

Àdínkù nínú gbogbo gbèdéke owó orí ẹrù / ọjà tí ó ní nǹkan ṣe pẹ̀lú òfin àwọn ayẹ̀wé-ẹrù-òfin òkèèrè-wò àti àwọn owó mìíràn tí ó lè ṣe okùnfà àmúgbòòrò àyípadà lọ́nà tí ó mú okòwò fẹjú sí i àti lórí àwọn èròjà èèlò ọjà mìíràn tó jẹ mọ́ irúfẹ́ nǹkan kan náà nínú ọjà. Bákan náà, ìgbésè bẹ́è yóò ṣe okùnfà ìkópa tí ó fẹjú bá okòwò ọlọ́pọ̀ ènìyan nínú ìpèsè ọjà láàrin agbègbè àti ní ìpele àgbáyé, níbi tí àwọn ọjà (ẹrù) yóò sì ti máa gba ẹnu ibodè wọlé láìmọye-ìgbà.

## *Òfin gbígbé ẹrù láti ibìkan sí òmíràn*

Nítorí pé owó-ǹ-san orí ọjà àti àkówọlé ẹrù láti òkèèrè ní àwọn òfin àtẹ̀lé kan, irú òfin onígbèdéke bẹ́ẹ̀ lè ní ipa lórí òfin ìpìlẹ̀ àti irú ẹrù tí ó jẹ́. Àwọn òdiwọ̀n kan wà tí yóò nílò láti fi mọ orírun tí ẹrù ọjà bẹ́ẹ̀ ti wá. Àwọn nǹkan wọ̀nyìí ni wọ́n kà sí àwọn òfin ìpìlẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n sì di igun pàtàkì mú nídìí ọ̀rọ̀ àdehùn ìdókòwò. Àwọn òfin ṣíṣé ojúṣàájú hànde, pàápàá, èyí tí ó wà lára àwọn òfin ìpìlẹ̀ tí wọ́n ń lò láti ṣe àmúlele fún ìlànà ṣíṣe ojúṣàájú nípasẹ̀ ìdásílẹ̀ rẹ̀; ìbèèrè wá ni pé, èwò nínú àwọn èèlò ìpèsè náà ni yóò ní àǹfààní láti tètè rí ààyè fún ojúṣàájú.

Gẹ́gẹ́ bí ó ti rí nínú àdéhùn olókoòwò aláìjẹ-mófin, ìdúnàà-dúrà lórí àwọn òfin ìpìlẹ̀ fún *CFTA* ṣe é ṣe kó jẹ́ èyí tó gbalẹ̀ kankan lórí àwọn ilé-iṣẹ́ ìdókòwò, tí ó bá ń wá ààyè fún ìṣojú-ṣàájú àti fún ìrànlọ́wọ́. Níbi tí ọ̀rọ̀ dé dúró, ìfọ̀rọ̀jẹ̀wọ̀ lórí èwo-lèwo ní sise ní, Ìwọ̀-oòrùn àti ààrin-gbùngbùn Aáfíríkà ní àwọn òfin gbogbo-gboò, tí ó jẹ́ àpapọ̀ òfin aténilọ́run, òfin ìpìlẹ̀, tí ó ṣe é se kí ó jọ òfin àwọn ènìyàn ilẹ̀ Ìlà-Oòrùn Asia àti agbègbè Pacific. Ní ẹ̀gbẹ́ kejì, Egypt, Kenya, àti South Aáfíríkà ti pè fún ṣíṣe àlàyé lójúnà àti mọ àwọn irú òfin ìpìlẹ̀, tí ó sì jẹ mọ́ irúfẹ́ kan ní-pàto; South Africa náà ti dọ́gbọ́n bèèrè fún ìrànlọ́wọ́ lórí

ìrànlọ́wọ́ lórí ọ̀nà àti-gba àṣẹ ìfọwọ́sí fún Orílẹ̀-èdè Southern Aáfírikà, ìtẹ̀síwájú ìdàgbàsókè àwọn èwe, òfin ìtẹ̀síwájú àwùjọ lórí òté kan fúnrẹ̀ àti àgbàjọ ìwé ẹ̀rí bẹ́ẹ̀ sínú àká wọn. Nítorí pé ìlànà ṣíṣe àyẹ̀wò gbígba ìwé-ẹ̀rí, ìbuwọ́lù rẹ̀ yàtọ̀ láti agbègbè kan sí èkejì, láàrin àwọn Àjọ Alájùmọ̀-jọṣe-pọ̀ lAáfíríkà (*REC*s); ṣíṣé ìtẹ́wọ́gbà òfin wọn kò yẹ kí ó nirà rárá; pàápàá tí ẹ̀rí àfihàn ìwoye àfojúsùn yìí ti sọ nípa iye ètò ìṣàkóso, tí kò sì tó iye tí àfojúsùn àtẹ̀yìnwà dábàá lọ. Nítorí náà, ó yẹ kí ó rọrùn láti fi ohùn ṣọ̀kan; lákọ̀ọ́kọ́ ná, láti jọ ṣe àgbéyẹ̀wò ọ̀nà tí wọn yóò fi ṣe àfiwé àwọn òfin tí ó rọ̀ mọ́ gbigba ìwé-ẹ̀rí ìjọba àti ẹ̀rí ìjẹ́rìí-sí gbígbà ìwé bẹ́ẹ̀. Ní ìyapa díẹ̀ sí èrò ìṣaájú, ìpèsè àkójọpọ̀ (àwọn ìṣòro tí ó bá ń dààmú àwọn agbègbè tàbí àwọn Orílẹ̀-èdè tí kò tí ì gbèrú tó àwọn yòókù nínú Àjọ náà, tàbí àwọn Orílẹ̀-èdè tí wọ́n ní ìwọ̀yá-ìjà mìíràn, tí ó yàtọ̀ sí ti akẹgbẹ́ wọn lórí àkójọpọ̀ ìṣẹ́ bẹ́ẹ̀ nínú ipò wọn) fún ọ̀nà àbáyọ nínú ìdojúkọ wọn, ó yẹ kí a mọ̀ pé ó yàtọ̀ láti agbègbè Àjọ (*REC*) kan sí ti ẹlòmìíràn.

## *Òfin "Ṣe é", "Má Ṣe é" fún Àwọn Aṣofin Ìdókòwò Alájùmọ̀ jọṣe-pọ̀*

Ó dájú pé gbogbo Orílẹ̀-èdè Aáfíríkà ni yóò gbé ìgbé ayé ìrọ̀rùn pẹ̀lú ànfàànì èrè tí ó dára nínú okòwò wọn, bí àgbékalẹ̀ ìdókòwò àjùmọ̀-jọṣe-pọ̀ tí ó dúró déédé bá wà; ó dára ju kí ó má sí rárá lọ. Kí wá ni àwọn àlàkalẹ̀ òfin tí ó ń ṣòdìwọ̀n ìdáhùn sí jíjẹ èrè tí ó rọ̀ mọ́ àgbékalẹ̀ ìdókòwò agbègbè alájùmọ̀-jọṣe-pọ̀ àti ọ̀nà àbáyọ sí ewu tí ó ń dènà àṣeyọrí àǹfàànì náà?

*Lákọ̀ọ́kọ́ ná, ìwọ̀nyìí ni àwọn nǹkan tí kò tọ̀nà fún àwọn aṣètò-ìlànà òfin àmúlò Ìdókòwò Àjùmọ̀-jọṣe-pọ̀ láti ṣe.*

- Má ṣe dààmú ara rẹ lórí àwọn àbùmọ́ ajẹmọ́-ohun tí ó lè ṣe òkùnfà jíju-àwà-sílẹ̀ nígbà tí ìyọnu lórí òfin àdáṣe àwọn ènìyàn Orílẹ̀-èdè bá yọjú, nítorí pé, àwọn òfin bẹ́ẹ̀ máa ń ṣe ìpèsè fún àgbéyẹ̀wò àwọn àlàkalẹ̀ òfin akójánu, ṣíṣe ìgbọkànlé nínú àwọn ènìyàn, kí a sì máa ṣe àyẹ̀wò àwọn ìyọnu tí ọ̀rọ̀ ọ̀ṣèlú lè mú wá fún àgbéjáde òfin mìíràn tí ó kapa ìṣòro alàìnìí-san-owó-ǹ-san orí ẹrù òfin.
- Má ṣe pa ìpèsè àwọn nnkan amáyérọrùn àrítọ́kasí tì (gbogbo òfin ìdásílẹ̀ rẹ̀ àti àwọn tí ó fara pé wọn), wọ́n ṣe pàtàkì láti lè jẹ èrè ìdókòwò, nínú ìpèsè àwọn ohun amáyérọrùn àrígbámú náà bí i (ìpèsè ojú-ọ̀nà ìrìn mótò, rélùwéè, àwọn arópòó-dògiri tí ó n sọ ìlú kan pọ̀ mọ́ òmíràn àti ìpèsè ìdíkò ìrìn ojú-omi).
- Má ṣe gbàgbó pé àjùmọ̀-jọṣe-pọ̀ okòwò nìkan ni yóò jé orísun èrè àti ìṣe amóríyá rẹpẹtẹ fún òrò ètò ìṣúná ní àwọn Orílẹ̀-èdè tí wón ti ní ìdàgbàsókè ju àwon kan lọ, nítorí pé ìrànlówó ìdókòwò fún ìṣúná wọn ti fẹjú yípo ní gbogbo ọ̀nà.
- Má ṣe fojú kéré pé, bí àwọn èròjà ìlò, oúnjẹ inú ilé kò ṣe lówó lórí tó ní àwọn àwùjọ kan, kí o wá ṣe àgbélé owó-ǹ-san fún àwọn ọjà bí i ìrẹsì àti ṣúgà, gẹ́gẹ́ bí àwọn èròjà tí owó òde orí wọn kì í gbéra ní àwọn agbègbè Ìwọ̀-Oòrùn àwọn Ìpínlẹ̀ Orílẹ̀–èdè Aáfíríkà àti ní (àwọn ibi tí ó ti máa n  keré jù lọ) ni Ìlà-Oòrùn agbègbè Aáfíríkà.
- Má ṣe ṣe àgbélé owó-orí fún irúfẹ́ àwọn ọjà kan ní pàtó, tàbí kí o yan àwọn irúfẹ́ ilé-iṣẹ́ kan ṣojú, lábẹ́ èrò pé ìpèsè òwò ọjà tiwọn yàtọ̀ lábẹ́ òfin ìpìlẹ̀. Àmọ́ àkọsílẹ̀ ìsọ̀rọ̀sí lábẹ́ òfin àlàkalẹ̀ kan fi hàn pé, àwọn agbẹnusọ òlùdókòwò ilẹ̀ Aáfíríkà kan ti ṣe àwárí àti ìṣàmì-sí fún àwọn èròjà ìpèsè láti ilé-iṣẹ́ bí i ọgọ́rún-ún mẹ́rin, fún àyànṣojú àti láti yanjú ọ̀rọ̀ tiwọn lọ́nà tí ó yàtọ̀.

*Ní báyìí, ẹ kíyèṣí àwọn Òfin Aṣeégbà fún Ìdókòwò ọjà*

- Ṣíṣe àmójútó ìtẹ̀síwájú lábẹ́ ète láti mú àdínkù bá owó-ǹ-san orí ẹrù-òfin-òwò àjùmòjọṣe-pọ̀ àti ìṣòro okòwò alàìní-owó-ǹ-san lórí, gẹ́gẹ́ bí àwọn àwùjọ kan ti ń ṣe ní ọjà àjọná pẹ̀lú àkọsílẹ̀ àṣeyọrí ọ̀rọ̀ ọja/ìdókòwò wọn, tí wọn sì n ṣe àkíyèsí ìsó ẹrù ní ìbámu pèlú òfin ìrìn alàìfòfin-dè-ẹrù, ìṣe àti àwọn ẹrù gbogbo.
- Ṣíṣe àyọkúrò gbogbo àwọn ìlànà òfin abojú-méjì alájùmọ̀-jọṣe òde-òní ní Aáfíríkà, kí a sì pa òfin ìpìlẹ̀ mọ́ lọ́nà tí kò nira kan-kan-an-kan, ṣùgbọ́n lọ́nà tí ó yéni, tí kò díjú, tí ó sì rọrùn láti ṣe àtúnṣe sí, àti lọ́nà tí kò farasin fún ẹnikẹ́ni. Yóò lè ṣe àfikún àjọsọpọ̀ inú-ilé lórí ìdókòwò Aáfíríkà láti nnkan bí i ìdá márùndín-lógún nínú ọgọ́rùn-ún, fún èrè nnkan bí i bílíọ́nù méjì dọ́là àti mejọ ($2.8 billion), ó lè kere lóòótọ́, ṣùgbọ́n ohun tí ó ye kí a dunnú sí ni; nítorí bí àkókò yìí ṣe rí, tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn adáàbò-bo òrò ètò ìṣúná n dìde fún òríṣìírísìí,

**Ṣíṣe àmójútó ìtẹ̀síwájú lábẹ́ ète láti mú àdínkù bá owó-ǹ-san orí ẹrù-òfin-òwò àjùmòjọṣe-pọ̀ àti ìṣòro okòwò aláìní-owó-ǹ-san lórí, gẹ́gẹ́ bí àwọn Àwùjọ Ìlà-Oòrùn Aáfíríkà (ÀÌA) - (EAC) ti ń ṣe pẹ̀lú àkọsílẹ̀ àṣeyọrí ọ̀rọ̀ ọja/ìdókòwò wọn, tí wọ́n sì ń ṣe àmójútó ìṣọ́ àti àyẹ̀wò tí ó yẹ, ní ìbámu pẹ̀lú àkólo-kóbọ̀ ẹrù ọjà wọn, láìní òfin kankan fún iye àkójọ owó ìdókòwò, ṣíṣe ojúṣe wọn, àti àwọn ẹrù tí ọ̀rọ̀ bá kàn.**

tí àyípadà sì n dé bá gbogbo nnkan nípasè òrò ètò ìṣúná tí ó jẹ́ ìṣe káríayé àti àwon ìṣèlẹ̀ èdè ìyapa láàrin Orílẹ̀-èdè *China* àti *United* irúfẹ́ ọjà tàbí irúfẹ́ òfin kan ní pàtó, tí ó sì jẹ́ ti ìpìnlẹ̀

- Àwọn òfin ìpìlẹ̀ yóò tún lè ṣe àmójútó ìdájó tí ó yẹ lórí àwọn òfin àgbékalẹ̀ ìjọba ọlójọ́ gbọọrọ, ní èyí tí ó kó ọ̀rọ̀ gbígba ìwé-ẹ̀rí, ìbuwọ́lù *States* bákan náà ni láàrin *Britain* àti *mainland Europe* tí ìyapa dé sí wọn.
- Ṣíṣe àfàyọ gbogbo ìṣòro àwọn ẹrù ọjà òkòwò tí kò ní owó-n-san orí ẹrù, àti owò iṣẹ́ àṣesin-ni inú okòwò, àti lórí àwọn ìdí pàtàkì tí wọ́n fi ṣe ìrànwọ́ fún orílẹ̀-èdè, níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé gbogbo akópa nínú okòwò ilẹ̀ Aáfíríkà ni wọ́n ṣe àmúlò òfin yìí fún káríkárí. Nígbà tí a bá ṣe àfikún àwọn owó-orí ẹrù tí a yọ kúrò, ìwọ̀nyìí yóo ṣe àfikún sí òwò àti ìgbérasọ àkójọpọ̀ èrè tí ó wọlé sí bílíọ̀nù mẹ́tàdín-lógóji dọ́là ($37 billion), àti pé èrè owó-n-san ti àgbáyé yóò ti gbéra di mílíọ̀nù mẹ́ẹ̀ẹ́dógún dọ́là ($15 billion), èyí tí ó kúrò ní kèrémí.
- Ìṣàmúlò àdéhùn ìrànlọ́wọ́ ìdòkòwò ní àfikún sí èròngbà *WTO's* máa ṣe àdínkù iye àkókò tí ó máa n gbàniyàn láti gbéra kúrò ní àwọn ẹnu ibodè náà, àti láti ṣe irúfẹ́ ìbádòwòpọ̀ tí ènìyàn bá fẹ́ ṣe níbẹ̀ láìjẹ́ pé iye owó jẹ́ àsomọ́ òdìwọ̀n owó-n-sàn. Bí a bá ṣe àfikún àyọkúrò owó-orí ẹrù yìí àti èyí tí kò ní ìṣòro owó-orí ẹrù, ó ṣe é ṣe kí ìyẹn náà fún wà ní àpapọ̀ èrè àníkún bí i ìdá méta-lé-ní ẹyọ hóró márùn-ún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún tí ó jẹ́ gbogbo èrè *GDP* lágbàáyé, tí ó fi sọ àpapọ̀ èrè náà di ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ iye ọgọ́rùn-ún bílíọ̀nù dọ́là.
- Ṣíṣe àgbéyẹ̀wò ipa tí àdínkù iye owó-orí ẹrù sísán máa ní lórí àwọn Orílẹ̀-èdè tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ n gbèrasọ, sísan ìlàjì iye tí ó yẹ kí wọ́n san, àti ìṣòro àìní-owó orí ẹrù sísan lórí àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n fún ní ìrànwọ́ ìyàsọ́tọ̀. Èyí náà lè ṣe okùnfà èlé èrè (GDP) ìdá mẹ́rin-lé-márùn-ún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún fún Aáfíríkà, àti fún àfikún bílíọ̀nù mọ́kànlélọ́gbọ̀n dọ́là ($31 billion), tí ó já sí pé gbogbo èrè yóò máa lọ sí bílíọ̀nù ọgọ́rùn-ún àti mẹ́rìnlé-lọ́gbọ̀n bílíọ̀nù dọ́là ($134 billion).
- Bákan náà, tí a bá ṣe àgbéyẹ̀wò ìdá ẹyọ Hóró méjì nínú ìdá ọgọ́rùn-ún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún owó-orí ẹrù sísan lórí ẹrù àkówọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn Orílẹ̀-èdè tí àwọn ní ọ̀nà àti gba owó gbọi wọlé. Ó lè mú ọgọ́rùn-ún lọ́nà

Ṣíṣe àwárí àti àmúlò òté ìrànlọ́wọ́ ìjọba fún ètò ìṣuná ní gbogbo agbègbè ṣe pàtàkì, kí a sì ṣe àmúlò òye ètò ìnáwó ní ọ̀nà tí kò mú ti ìná àpà dani, kí a sì máa ṣe àmójútó bí owó ṣe n wọlé-jáde.

méjọ àti ààdọ́ta mílíọ̀nù dọ́là ($850 million) wọlé lọ́dún láti ṣe ètò ìrànwọ́ ìdókòwò.

*Ní pàtàkì, kí a gbé ìgbésẹ̀ ìdásílẹ̀ ìpèsè ẹrù ìlò fún àwùjọ lágbègbè, èyí kì í ṣe ọgbọ́n àgbọ́nforo, nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ Orílẹ̀ -èdè ni wọ́n ti jẹ àǹfààní rẹ̀, ní pàtàkì jùlọ ni àwọn Orílẹ̀-èdè tí wọn kò ní ọ̀nà tí owó fi ń wọlé fún wọn rẹpẹtẹ.*

- Ṣe ìfẹ̀gbékẹ̀gbé òté ètò ìṣúná ìjọba yíká agbègbè, kí a sì ṣe àmójútó òté àyẹ̀wò bí owó ṣe ń yí wọlé-jáde sí, nígbà tí a ń ṣe àyọkúrò àwọn ìṣòrò onígbèdéke ibi tí kò tọ̀nà tí ìnáwó ń gbà yọjú ní ẹnu-bodè, àti láti ṣètò àwọn ìdúnàá-dúra tí ó bá yẹ..
- Ó ṣe pàtàkì láti lo agbára, láti lè je àǹfààní ninla tí ó wà nínú ètò ìdókòwo ẹnu-ibode ìlú-sí-ìlú nínú ibi tí àǹfààní iná mọ̀nà-mọ́ná náà tún wà. Gẹ́gẹ́ bí *Nord Power Pool* ní Àríwá ilẹ̀ Europe ti se àfihàn rẹ̀, ó dára láti bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àwọn Orílẹ̀-èdè kekeré, kí a sì sinmi lé ètò ìnáwó òde láti ṣe àfikún agbára, ààyè àtilẹ̀ṣe, kí a ṣe àkópọ̀ àwọn ìran tí wọ́n ṣẹ̀dá pẹ̀lú yíyọ̀nda rẹ̀ síta; bákan náà, kí a ní ìwọ̀n tí ó tó láti ṣe àgbédúró agbára ìpèsè síta; àti láti múra sí títẹ́wọ́gba àwọn èròjà ọjà náà, kí a sì fi ààyè gba orógún òwò ṣíṣe.
- A gbọ́dọ̀ ṣí ìlẹ̀kùn wa sílẹ̀ gbàragada fún ìfààyè gba ìfagagbága òwò, gẹ́gẹ́ bí ó ti rí ní Mozambique, tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ fí ààyè gba àwọn Ìdókòwò ọjà Mọ́tò (*Transport Market*) láàrin wọn, ní èyí tí wọ́n ṣe ìfilọ́lẹ̀ rẹ̀ ní Oṣù Kìn-ín-ní ọdún 2019; ìgbésẹ̀ wọn náà sì ti di ohun tí àwọn Orílẹ̀-èdè méjìlélógún ti buwọ́lù bayìí. Márùndínlọ́gọ́rin nínú ìdá ọgọ́rùn-ún jẹ́ Okòwò-ọkọ̀-Òfùùrufú alájùmọ̀jọṣe-nilẹ̀ Aáfíríkà (intra-African air transport). Òfin àlàkalẹ̀ kan tí àwọn Ìjọba Morocco pè ní “Morocco open skies policy” ṣe àfihàn bí ṣíṣe àdínkù bá owó-ǹ-san ọkọ̀-Òfùùrufú àti bí pípèsè àwọn ọ̀nà mìíràn ṣe lè ṣe àfikún ààyè ìjókòó sí i pẹ̀lú, níbi tí a bá ti fi ìlàjì sílẹ̀ (dípò ìdá mẹ́wàá ní Tunisia) àti láti ṣe ìgbesókè ìpín àwọn ọkọ̀-Òfùùrufú tí owó-n-san wọn kì í wọ́n gege láti ìdá méta ní ọdún 2006 sí ìdá mẹ́rìndínlọ́gbọ̀n ní ọdún 2010 (èyí já sí pé, láti ìdá méje ni ó ti lọ sí ìdá mẹ́wàá ní Tunisia nìkan).
- Ṣíṣí ẹnu bode sílẹ̀ fún àǹfààní lílo-bíbọ̀ láìmú-òfin dan-in dan-in dáni fún àwọn ènìyàn — bóyá, nípa ṣíṣe àyẹ̀wò, gbígbàwọlé àti ṣíṣe àmúlò ìwé ìrìn-nà Àpapọ̀ ẹgbẹ́ ọmọ Aáfíríkà (African Union Passport) tí wọ́n ṣe ìfilọ́lẹ̀ rẹ̀ ní ọdún 2016, kí a sì rí i pé ó wà ní ìlò káríkárí láti ọdún 2020.

*Àpótí Kìn-ín-ní: Ṣíṣe àyípadà sí àwọn ìlànà àti òfin àtẹ̀lé fún Àjọṣepọ̀ Agbègbè*
*Díẹ̀ nínú àwọn òfin àtẹ̀lé fún àgbéyẹ̀wò níbi ìpàdé Àjọṣepọ̀ ilẹ̀ Aáfíríkà fún onírúurú àyípò-pàdà lórí ọrọ̀-ajé nìyìí:*

*Àwọn ibùdó tí ọrọ̀-ajé wọn wà láàrin gbùngbùn - Botswana, Burkina Faso, Burundi, Central African Republic, Chad, Ethiopia, Lesotho, Malawi, Mali, Niger, South Sudan, eSwatini, Rwanda, Uganda, Zambia, àti Zimbabwe.*

- Ìgbìyànjú onítẹ̀síwájú fún ṣíṣe ìpèsè aṣojú fún agbègbè lórí èlò ọjà fún àwùjọ.
- Ìtẹ̀síwájú lórí ìpèsè àwọn ohun amáyérọrùn oníbejì bi i ọ̀nà rélùwéè, ojú-ọ̀nà mótò, ojú-ọ̀nà fún ọkọ̀ òfuurufú, àti àwọn ojútò fún ọ̀pá ìbánisọ̀rọ̀ fún ànfààní Orílẹ̀-èdè.
- Láti ṣe àfikún agbára ìpèsè àwọn ọkọ̀ ìrìnàjò lórísìírísìí, lábẹ́ àkóso Àjọ *Northern Corridor Transit and Transport Agreement* - Àríwá tí ó pèsè ọkọ̀ Ìrìnnà àti Àdéhùn Ohun Ìrìnnà, fún àwọn ìrìn-àjò tí ó nasẹ̀ díẹ̀, owó ọkọ̀ fún ìrìn ní àárín ọdún 2011 sí 2015, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé owó-n-san fún ọkọ̀ gbówó lórí, owó wálè sí ìdá àádọ́rin nínú ìdá ọgọ́rùn-ún láti Mombasa sí Kampala àti sí ìdá ọgbọ̀n nínú ìdá ọgọ́rùn-ún, láti Mombasa sí Kigali. Ní ìyapa sí èrò àtẹ̀yìnwá, wọn gbèrú lọ́nà kan náà pẹ̀lú *Central Corridor* tí ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ ìdá ọgọ́rin nínú ìdá ọgọ́rùn-ún láti Dar sí Kampala; bákan náà, pẹ̀lú ìdá mẹ́rìndínlógójì nínú ìdá ọgọ́rùn-ún láti Dar lo sí Kigali. Ìyàtọ̀ pàtàkì tí ó wà níbẹ̀ ni pé, ààtò tó já sí ìtẹ̀síwájú rere farahàn nínú ìgbésẹ̀ *Northern Corridor*.
- Ìdápadà ìlànà òfin abàṣẹwàá. Ọ̀pọ̀ àwọn Orílẹ̀-èdè tí omi yí ká, tí wọ́n wà láàrin gbùngbùn Aáfíríkà, ni ó jẹ́ pé owó tí ó ń wọlé fún wọn kéré, wọ́n ń gbìyànjú láti kópa nínú ìdókòwò agbègbè inú ilè Aáfíríkà ju òwò ilẹ̀ omi tàbí láàrin àwọn Orílẹ̀-edè tí ó rí tajé ṣe gidi lọ. Ṣùgbọ́n, òdiwọ̀n kan tí a ṣe fi hàn pé ìdá mẹ́tàdínlọ́gọ́rin nínú ìdá ọgọ́rùn-ùn òwò àkójáde wọ́n ní àǹfààní ìdì tí ó ní àkóónú iye owó mọ́tò, tí í ṣe ìdíwọ́ ńlá tí ó ga sí àgbègbè wọn àti ìdókòwò àgbáyé.
- Èròngbà láti ṣe àfikún ọgbọ́n tí ó lè ṣe ìtẹ̀síwájú fún àwọn nǹkan àfẹnukò lórí bí ọ̀rọ̀ ṣe máa ń rí tẹ́lẹ̀ àti àwọn ohun èèlò tí ó lè ṣe ìrànlọ́wọ́ ìdìde òwò àgbékiri náà (kọjá ìdúnàá-dúrà àdéhùn abẹ̀jì tí wọ́n ṣe lọ).

*Fún ọrọ̀-ajé àwọn Orílẹ̀-èdè ilẹ̀ omi tí wọ́n wà aàrin gbùngbùn - Algeria, Angola, Benin, Cabo Verde, Cameroon, Comoros, Congo, Democratic Republic of Congo, Côte d'Ivoire, Djibouti, Egypt, Equatorial Guinea, Eritrea, Gabon, Gambia, Ghana, Guinea-Bissau, Kenya, Liberia, Libya, Madagascar, Mauritania, Mauritius, Morocco, Mozambique, Namibia, Nigeria, São Tomé and Príncipe, Senegal, Sierra Leone, Somalia, South Africa, Sudan, Tanzania, Togo, àti Tunisia.*

- Ṣe ìfẹ̀lójú ibùdó ọkọ̀ ojú-omi gbogbo, títí dé orí àwon ohun àfipamó àti ìsàkóso ìse àwon ayèwé- ẹrù òfin- ẹnu bode-wò, bákan náà, kí àfikún agbára ìlànà àmójútó lílo-bíbọ̀ ọkọ̀ lójú pópó, àti gbígbé ẹrù tó jẹ mọ́ kọ̀nténà. Àfojúsùn ìpèsè ààyè fún ibùdókọ̀ oju-omi àti iye owó ọkọ̀ ojú-omi ilè Aáfíríkà tí a wòye jẹ́ ìdá ogójì nínú ìdá ọgọ́rùn-ún, tí ó ju iye ìṣe káríayé lọ wọ́n sì tún ní ààyè tí kọ̀nténà lè dúró dà, ìdádúró àìtètè ṣe ìwé gbígba ìwé ìrìn ẹrù, ọjọ́ pípé kí ìwé ẹrù tó jáde àti iye kọ̀nténà tí mọ́tò akẹ́rù lè gbé ní òdiwọ̀n láàrin wákàtí (àyàfi ní South Africa nìkan ni gbédéke òfin bẹ́ẹ̀ kò ti sí). Ní kúkúrú, ju ìdá àádọ́rin nínú ìdá ọgọ́rùn-ún ìdádúró ni àkókò tí erù fi n wà kí ní ìdádúró, kí ó tó jẹ́ gbígbà jáde láti àwọn ìdíkọ̀ ojú-omi.
- Àfikún ìyára-ṣe-iṣẹ́ nínú bí wọ́n ti ń ṣiṣẹ́ sí, ìfọkàntán àwọn rélùwéè àti gbogbo ojú-ọ̀nà nípasè àdínkù ìgbòkè-gbodò mọ́tò tí kò fi ní í sí ìdádúró ní gbogbo àwọn bodè tí wọ́n ti n yẹ ẹrù wò, àti àwọn ibùdó ìyàbàrá nítorí àwọn mọ́tò akẹ́rù-nínlá àti ṣíṣe àmójútó àtúnṣe ibùdó ìkẹ́rùsí.
- Títẹ̀-n-pẹlẹ mọ́ àtúnṣe ìlànà ààtò nǹkan bí ó ti ṣe máa ń rí tẹ́lẹ̀ àti àwọn èròjà ìlò, tí ó kọjá ìdúnàá-dúrà abẹ̀jì-ìṣe láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún okòwò alágbèèká.

Fún àwọn Orílẹ̀-èdè tí wọ́n ní Ọrọ̀-Ajé *tó fẹjú — Egypt, Morocco, Nigeria, àti South Africa*

- Jẹ́ aṣiwájú rere láti tukọ̀ kí ẹgbẹ́ kan wà, tí yóò máa ṣàmójútó kí àwọn àyẹ̀wé-ẹrù òfin wò gba yíyan aṣojú, níbi tí wọ́n yóò ti máa ṣe òfin láti mú kí àwọn tí wọ́n ń ṣòfin látòkè lè gba àbá pé kí wọ́n ta ko èrò ayọnilẹ́nu, tí ó lè ṣàkóbá fun ọjọ́ iwàju àwọn tí ó ń pèsè àwọn èròjà ìlò nínú ilé àti ìwòn sí ṣíṣe ìfagagbága okowò.

*Fún Orílẹ̀-èdè tí wọ́n ní àwọn èròjà ànihun-lọ́rọ̀ kún ọrọ̀-ajé - Botswana, Democratic Republic ti Congo, Ghana, Guinea, Mozambique, Namibia, Niger, South Africa, Tanzania, àti Zambia*

- Ṣe àmúlò òté rere tí àwọn *National Resource Charter* lò.
- Fọwọ́-sowọ́pọ̀ láti ṣe àmúlò àtìlẹ́yìn sísan owó-orí ìlò epo, gáàsì, àti àwọn ohun àlùmọ́nì ọ̀rọ̀ ilẹ̀, kí a lè yàgò fún ewu àìyédè láti ìpìlẹ̀ àti àwọn àsomọ́ ìyànjẹ mìíràn tí ó yí i ká.